# Jèhófà-Jírè Apá Kinni

Louisville, Mississippi, USA

Ọjọ Keji, Oṣu Kẹrin, 1964

1 Ẹ joko. Anfaani nla ni eyi jẹ lati tun pada wa ni aṣalẹ yii, ibukun nla si ni fun mi lati wa ba yin sọrọ nipa Jesu Oluwa wa (ẹniti o da mi loju wipe ọpọlọpọ yin mọ, tabi ti mo ni ireti wipe ẹ mọ), ati idariji awọn ẹṣẹ yin, ati … nipa oore-ọfẹ Rẹ si yin. Ki O fun yin ni oore-ọfẹ Rẹ si i ni aṣalẹ yii. Nigbati a ba kuro nibi yii, ki a lee sọ bii awọn ti wọn n bọ lati Emmausi, wipe, “Ọkan wa gbina ninu wa loju ọna.”

Ni bayi, ni gbogbo owurọ,

2 Mo gbagbọ wipe wọn ni agbẹnusọ awujọ kan bii… Ọgbẹni Vayle n ṣe idanilẹkọ kan - o n dahun awọn ibeere kan, o si n sọrọ nipa Iwe Mimọ (Ṣe ninu ile yii ni?), ninu ile yii ni owurọ ọjọ kan. Bi ẹnikẹni ba ni ominira, boya iranṣẹ Ọlọrun tabi ẹlomiran, ti ẹ ba fẹ wa, gbogbo yin ni aaye wa fun. Arakunrin Vayle jẹ olukọ gidi, ti o kawe gidi.

3 Nitorinaa…

Mo sọ ni ijelo wipe o wu mi ki n ka iwe. Mo nilati maa lo awọn owe, bii ki a fi nkankan ṣalaye nkan miiran, ṣe ẹ mọ. Emi ko ka iwe to lati fọ ọ si wẹwẹ. Ṣugbọn lọna kan tabi omiran, Oluwa n ran mi lọwọ lati lu aluyọ.

Mo ranti wipe ọkunrin kan wa ninu Iwe Mimọ ni igba kan, Johanu ni orukọ rẹ. Alufaa ni baba rẹ. Wọn maa n saabaa ṣe iṣẹ ti baba wọn ba n ṣe. Ṣugbọn o ni iṣẹ-iranṣẹ iwaasu kan. Oun ni o nilati kede Messiah. Ni bayi, iba ṣe wipe o lọ si ile-iwe ti baba rẹ lọ ni, wọn iba sọ pe, “Bayi o, ṣe o mọ Arakunrin Lagbaja, oun ni messiah.” Wọn yoo fẹrẹ lee fi ọrọ yi i lọkan pada. Nitorinaa, ko lọ si iru ile-iwe bẹẹ.

4 O lọ sinu aginju nibiti o ti kọ nipa Ọlọrun.

Ṣe ẹ kiyesi bi iwaasu rẹ ṣe ri? Ko ka iwe kankan. O lọ sinu aginju ni ọmọ ọdun mẹsan, o si jade ni ọmọ ọgbọn ọdun, o waasu fun oṣu mẹfa, a si pa a. A ri i wipe o maa n lọ, o ni… Bii igbati awọn Farisi ati awọn Sadusi jade wa. O ni, “Ah, ẹyin ọmọ paramọlẹ!” Ohun ti o n ri ninu aginju niyẹn - ejo, ohun kan ti o maa n fa nilẹ, alarekereke, ẹlẹtan, ṣe ẹ ri i.

Ẹnikan lee sọ pe, “Kini, iwọ oniwahala ti ko jamọ nkankan,” tabi nkankan. Ṣugbọn o … ṣugbọn ẹ wo o, ko mọ ọrọ ti o lee lo, nitorinaa, o wipe, “Ẹyin ọmọ paramọlẹ.” Ohun ti o ri ninu aginju niyẹn. O ni, “Tani o kilọ fun yin lati sa kuro ninu ibinu ti n bọ? Ẹ maṣe maa wipe 'A ni … awa jẹ ọmọ ijọ yii, awa jẹ ọmọ ijọ yẹn, nitori Ọlọrun lee gbe ọmọ dide [ohun ti o n ri ni] fun Abrahamu. A si ti fi aake le gbongbo igi naa.” O mọ ohun ti a lee ṣe si igi buburu. “Ohun gbogbo ti ko ba so eso rere ni a o ge lulẹ, ti a o si wọ ọ ju sinu ina,” lati fi igi buburu jona.

Ṣe ẹ ri i, o … gbogbo iwaasu rẹ da lori ẹda. O ṣe afiwe rẹ. Iyẹn ni o ye awọn mẹkunnu. Nitorinaa, wọn… Igbamiran, mo ro wipe iyẹn yoo mu ki o ye wọn ju gbogbo awọn ọrọ nla ti awọn eniyan n kọ ni ile-iwe.

5 A pẹ diẹ ni alẹ ana, nitorinaa, a o gbiyanju lati jẹ ki e tete jade ni alẹ oni, ti a ba lee ṣe bẹẹ. Mo si gbagbọ wipe Oluwa ki yoo jẹ ki ojo rọ pupọ ni aṣalẹ yii, lori orule paanu yii. Nitorinaa, a … a gbagbọ, a si n gbiyanju lati sin-in pẹlu gbogbo agbara wa.

6 Ẹ jẹ ki a dide duro bi a o ṣe ka Ọrọ Ọlọrun. A o ka lati inu iwe Gẹnẹsisi, a o bẹrẹ pẹlu ori kejilelogun, lati ẹsẹ ikeje, titi de ẹsẹ ikẹrinla:

Isaaki si sọ fun Abrahamu baba rẹ, o si wipe, Baba mi: oun si wipe, Emi niyi, ọmọ mi. Oun si wipe, Wo ina oun igi, ṣugbọn nibo ni ọdọ-aguntan ẹbọ sisun naa gbe wa?

Abrahamu si wipe, Ọmọ mi, Ọlọrun tikalarẹ ni yoo pese ọdọ-aguntan fun ẹbọ sisun: bẹẹni awọn mẹjẹeji jumọ n lọ.

Wọn si de ibi ti Ọlọrun ti wi fun-un; Abrahamu si tẹ pẹpẹ kan nibẹ, o si to igi rere, o si di … Isaaki ọmọ rẹ, o si da a dubulẹ ni ori pẹpẹ lori igi naa.

Abrahamu si na ọwọ rẹ, o si mu ọbẹ naa lati dumbu ọmọ rẹ.

Angẹli Oluwa nni si kọ si i lati ọrun wa, o wipe, Abrahamu, Abrahamu: o si dahun pe, Emi niyi.

O si wipe, Maṣe fọwọkan ọmọde nni, bẹẹni iwọ ko gbọdọ gbe … ọwọ le e: nitori nisisiyi emi mọ pe iwọ bẹru Ọlọrun, nigbati iwọ ko ti du mi ni ọmọ rẹ, … naa kanṣoṣo.

Abrahamu si gbe oju rẹ soke, o wo, si kiyesi i, lẹyin rẹ, agbo kan ti o fi iwo rẹ ha ni pantiri; Abrahamu si lọ, o mu agbo naa, o si fi i rubọ sisun ni ipo ọmọ rẹ.

Abrahamu si pe orukọ ibẹ naa ni Jehofa-jire: bi a ti n wi titi di oni yii, Ni oke Oluwa ni a o gbe ri i.

7 Ẹ jẹ ki a tẹriba fun iṣẹju kan lati gbadura. Baba wa ọrun, a sọ fun wa nipa Ọrọ yii, eyiti iṣe Ọlọrun, wipe igbagbọ n wa nipa gbigbọ, ati gbigbọ Ọrọ Ọlọrun. Ni bayi, Baba, a gbadura wipe ki o fun wa ni itumọ iwe kika yii, ki a lee kọ ẹkọ, bi a ti sọ fun wa ninu Bibeli, wipe ohun gbogbo ti o wa ni Majẹmu Laelae jẹ apẹẹrẹ, ki a lee ri i wipe gbogbo awọn ti wọn gbọran si ipe Ọlọrun jẹ ẹni ibukun; awọn ti o kọ ọ di ẹni ifibu. Nitorinaa, a gbadura, Baba, wipe ki a ni oye ni aṣalẹ yii nipa ifihan. Jẹ ki Ẹmi Mimọ fihan fun wa, awọn nkan ti o jẹ mọ wa lọjọ oni, eyiti o farasin sinu ijinlẹ nla ti Ọlọrun yii, eyiti o ti wa lati ipilẹṣẹ aye. Nitoriti a beere ni orukọ Jesu. Amin. Ẹ joko.

8 Bi Oluwa ba fẹ, mo fẹ sọrọ lori akori kan, lati inu èrò “Jehofa-jire.” Itumọ ọrọ naa ni, “Ọlọrun yoo pese ẹbọ fun ara Rẹ.” A n sọrọ nipa Abrahamu. Eyi jẹ akoko ti o n foju sọna fun ọmọ ti a ṣe ileri rẹ.

Lati mọ otitọ ọrọ yii, a o pada sẹyin. Eyi wa ni ori kejilelogun. A fẹ pada yẹ ẹ wo. Mo ni awọn ẹsẹ Iwe Mimọ diẹ ti mo kọ silẹ, eyiti n o tọka si, ti o ba ṣee ṣe, mo si fẹ sọrọ nipa wọn. Mo fẹ bẹrẹ lati ori kejila.

A o pada lọ wo ẹniti Abrahamu jẹ. Ati wipe bawo ni Ọlọrun ṣe yan-an?

9 A mọ wipe a fun Abrahamu ni ileri naa, ati iru-ọmọ rẹ lẹyin rẹ; nipa wiwa ninu Abrahamu nikan ni a fi jẹ ajumọjogun ileri naa pẹlu rẹ. Abrahamu ni iru-ọmọ, iru-ọmọ naa si ni, … O ni ọpọlọpọ iru-ọmọ. Ṣugbọn o ni iru-ọmọ kan ti ileri naa wa fun.

O ni Iṣmaeli. Lẹyin ti Sarah ku, o fẹ obinrin miiran, o si bi awọn ọmọkunrin meje yatọ si awọn ọmọbinrin. Iru-ọmọ Abrahamu ni gbogbo wọn, ṣugbọn … iru-ọmọ Abrahamu ni wọn, ṣugbọn iru-ọmọ naa ni eyiti o ni ileri. Iru-ọmọ naa ni igbagbọ Abrahamu, eyiti o ni ninu ileri Ọrọ Ọlọrun.

10 A ri i wipe Abrahamu ko farahan bikoṣe igba ti a ri i ni ori ikejila. Ni ori ikọkanla iwe Gẹnẹsisi, a ri i wipe baba rẹ ṣokalẹ wa lati Babiloni, Abrahamu si jẹ eniyan lasan bii iwọ ati emi, tabi ẹnikẹni. O si ti n di arugbo. Ọmọ ọdun marundinlọgọrin ni. O fẹ aburo rẹ obinrin ti o jẹ ọmọ baba rẹ. Sarai ni orukọ rẹ. Orukọ rẹ kii ṣe Abrahamu nigbanaa. Abramu ni, tirẹ naa si n jẹ Sarai. A si ri i wipe o fi ọdun mẹwa din si iye ọdun Abrahamu, eyiti o mu ki oun jẹ ọmọ ọdun marundinlaadọrin, nigbati oun jẹ ọmọ ọdun marundinlọgọrin.

11 Wọn … boya agbẹ ni, ti o n gbe afonifoji Sinari - wọn n gbe igbe-aye mẹkunnu. Boya ni ọ̀sán, yoo jade lọ lati wa ounjẹ, yoo wa awọn èso, bi o si ṣe n gbe igbe-aye rẹ niyẹn - eniyan lasan ni. Ko si ohun kan ti o yatọ nipa rẹ.

Ṣugbọn lọjọ kan, Ọlọrun pe e. Ohun ti o mu iyatọ wa niyẹn, nigbati Ọlọrun pe e. Bi o ṣe ri si gbogbo eniyan niyẹn. O gba Ọlọrun. Kii ṣe ohun ti o ṣe; ohun ti Ọlọrun ṣe ni. O lee sọ pe, “Mo wa Ọlọrun, mo wa Ọlọrun.” Aṣiṣe ni o ṣe. Ko si eniyan kankan ti o n wa Ọlọrun; Ọlọrun ni o n wa eniyan, ṣe ẹ ri i. Kii ṣe iwọ ni o n wa Ọlọrun; Ọlọrun ni o n wa ọ. Jesu wipe, “Ẹyin kọ ni o yan mi; ṣugbọn Emi ni mo yan yin,” ṣe ẹ ri i.

Nitorinaa, a ti yan ọ ṣaaju ipilẹṣẹ aye, aijẹbẹẹ, a ko yan ọ rara. Ó kan wa lati ra orukọ yẹn pada ni. Gbogbo awọn ti orukọ wọn ko ba si ninu iwe iye Ọdọ-aguntan naa ṣaaju ipilẹṣẹ aye ni yoo wa nibẹ. A ti yan ọ tẹlẹ ninu Rẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye. Nigbati a yan Ọdọ-aguntan naa, a yan ọ pẹlu Rẹ, ṣaaju ipilẹṣẹ… Bi mo ṣe sọ ni alẹ ana, o jẹ èrò ninu ọkan Ọlọrun. Iyẹn nikan ni … o fi lee jẹ ẹni ainipẹkun. Iye ainipẹkun kanṣoṣo ti o wa … oriṣi iye ainipẹkun kanṣoṣo ni o wa, iyẹn ni Ọlọrun. Ko ju bẹẹ lọ. Oun ni o jẹ ainipẹkun.

12 Ni bayi, a ri i wipe Abrahamu ni o ni ibẹyẹn. Ọlọrun, ni Majẹmu Laelae, n ṣiṣẹ pẹlu apẹẹrẹ ati ojiji, lati fi ohun ti O fẹ ṣe han. A ri i wipe Ọlọrun ba a sọrọ nibi yii. Ohun nla ti o wa nibẹ ni wipe, lẹyin ti Ọlọrun ti pe e… Ipe ti Ọlọrun fi pe e jẹ ipe iyanu, ṣugbọn sibẹ, ko mu ki Abrahamu kọsẹ - ko si akoko kankan ti o kọsẹ. O mọ nigbagbogbo wipe Ọlọrun ni. Nkan nla niyẹn. Nigbati… awọn ipe Ọlọrun jẹ iyanu; ko si ti ẹran-ara nibẹ… Ọlọrun n mu nkan iyanu, O si fi n sisẹ ninu ara - ṣugbọn awọn ipe Ọlọrun jẹ iyanu. Bibeli wipe, “ipe ati ẹbun ko ni ironupiwada ninu.” Ṣe ẹ ri i, Ọlọrun ti yan-an tẹlẹ ni.

13 A ri i ninu eyi wipe nigbati a pe Abrahamu, o gbọ ohun Ọlọrun. O sọ ohun ti o dabi ẹni wipe ko ṣee ṣe rara fun-un. Oun ti o jẹ ọmọ ọdun marundinlọgọrin, iyawo rẹ jẹ ọmọ ọdun marundinlaadọrin (iyẹn ni wipe o ti fi bii ogun ọdun kọja akoko ti o lee ri nkan oṣu), o si ti n ba a gbe lati igba ti o ti wa ni ọdọmọbinrin, wọn ko si ni ọmọ kankan; sibẹ, O sọ fun-un wipe wọn yoo bi ọmọ kan. Ati wipe nipasẹ ọmọ yii ni a o bukun fun gbogbo aye, ani gbogbo orilẹ-ede.

Ohun ajeji niyẹn.

14 Bibeli sọ ninu iwe Roomu ori kẹrin wipe Abrahamu “ko fi aigbagbọ ṣiyemeji ileri Ọlọrun; ṣugbọn o le ni igbagbọ, o n fi ogo fun Ọlọrun.”

Mo lee fi oju inu wo o wipe lẹyin oṣu kinni… Gẹgẹbi mo ṣe sọ, Sarah ko ri nkan oṣu mọ. Oṣu kinni, mo

lee fi oju inu wo o wipe Abrahamu sọ pe, “Sarah, bawo ni ara rẹ ti ri, olufẹ?”

“Ko si iyatọ.”

“Ko buru, ibukun ni fun Ọlọrun. A o bi ọmọ naa lọnakọna. A o bi i. Ọlọrun sọ bẹẹ.”

15 Sarah n hun aṣọ ọmọde, o ti ra bata, ati ìkọ́, ati ohun gbogbo - o ti mura silẹ, o n mura silẹ fun-un, nitoriti o mọ wipe oun yoo bi ọmọ naa. Ọlọrun sọ bẹẹ.

Ọdun kinni kọja. “Ṣe iyatọ wa, olufẹ?”

“Ko si iyatọ rara.”

“Ẹ yin Ọlọrun. Yoo jẹ iyanu nla bayi ju bi o ṣe ri ni akọkọ lọ. [Ṣe ẹ ri i, lẹyin ọdun kan.] Yoo bi ọmọ naa lọnakọna. [Kini idi?] Ọlọrun sọ bẹẹ. O pari. Ọlọrun sọ bẹẹ. Awa … Ọlọrun sọ bẹẹ.”

Ọdun mẹwa ti kọja. “Bawo ni ara rẹ bayi, olufẹ?” Oun ti di ọmọ ọdun marundinlọgọrin bayi, ọkọ rẹ si ti di ọmọ ọdun marundinlaadọrun. Njẹ ẹ lee ro o wipe ki baba arugbo ati iya arugbo bẹyẹn loni, ki wọn lọ si ile-iwosan, ki wọn si wipe, “Dokita, a fẹ ṣe imurasilẹ?”

16 Ọlọrun maa n sọ wipe ki a gba awọn nkan ti ko mu ọgbọn dani gbọ; ṣugbọn O maa n mu u ṣẹ nigbagbogbo. Ọlọrun…

Ẹniti o ba gba Ọlọrun gbọ patapata maa n dabi were loju aye. Njẹ ẹ lee fi oju inu wo Mose, ẹniti a kọ ni gbogbo ọgbọn Egipti, olori awọn ọmọ-ogun … ọmọ-ogun Egipti - sibẹsibẹ… Ogoji ọdun ni o fi kọ ẹkọ yẹn; Ọlọrun si lo ogoji ọdun lati mu ẹkọ yẹn kuro ninu rẹ - ohun ti o na aye lati fi sinu rẹ naa niyẹn. Lẹyin ogoji ọdun si i, Ọlọrun kọ ọ, O mu gbogbo iwe kika ati ẹkọ-ẹsin ti o wa ninu rẹ kuro. O si ba a pade ni aṣálẹ̀. O mọ nipa Ọlọrun ni iṣẹju marun-un niwaju Ọlọrun ju ohun ti o fi ogoji ọdun kọ ninu iwe. Bẹẹ ni.

17 A ki i mọ Ọlọrun nipa iwe kika; igbagbọ ni a fi n mọ Ọlọrun. Ọlọrun si ba a sọrọ lọna iyanu.

Igbamiran, Ọlọrun maa n mu ki a ṣe ohun ti ko ba ọgbọn mu. Njẹ ẹ lee ronu nipa ọkunrin arugbo kan, ọmọ ọgọrin ọdun, ki o maa sá (wolii ni), sá fun Ọlọrun? Iṣẹju marun-un niwaju Ọlọrun… Ni owurọ ọjọ keji - njẹ ẹ lee fi oju inu wo o - baba arugbo kan, pẹlu irun-imu rẹ ti o ṣàn walẹ, ori rẹ pá, o si n dan, ọpa wiwọ kan wa lọwọ rẹ, iyawo rẹ joko sori ibakasiẹ, pẹlu ọmọde kan ni ori itan rẹ, wọn n lọ si…

“Nibo ni o n lọ, Mose?”

“Mo n lọ si Egipti, lati gba ijọba.” Gba ijọba kẹ? Igbogunti lati ọwọ ọkunrin kanṣoṣo!

Iyẹn ko ba ọgbọn mu. Ṣugbọn ohun ti o wa nibẹ ni wipe, o ṣe e - nitoriti Ọlọrun sọ bẹẹ. Iyẹn ti yanju ọrọ. Nigbati Ọlọrun ba ti sọ bẹẹ, o pari niyẹn. Bi o ṣe ri niyẹn. Ti Ọlọrun ba ti ṣe ileri, so ọkan rẹ rọ mọ ọ. Ti o ba lee gba a gbọ, fi ọkan rẹ si i… Ti o ko ba gba a gbọ, takete si i - yoo pa ọ lara. Ṣugbọn ti o ba gba a gbọ, duro ti i. Yoo mu ọ de ibi iṣẹgun, dajudaju.

18 A ri i wipe Abrahamu ko ṣiyemeji ileri Ọlọrun. Nigbati o pe ọmọ ọgọrun ọdun, ti oun naa si jẹ ọmọ aadọrun ọdun, mo lee gbọ ọrọ rẹ. Ko lee sọrọ pupọ mọ bayi, o ti n di arugbo ati alailera.

“O dara, Sarah olufẹ, bawo ni ara rẹ?”

“O dara, Olufẹ mi, ko si iyatọ.”

“Halleluya! A o saa bi ọmọ naa. Ọlọrun ti sọ bẹẹ. Ko ju bẹẹ lọ. Ọlọrun ni o fun wa ni ileri naa.” O sọ pe o ni idaniloju wipe Ọlọrun lee ṣe ohun ti O ti ṣe ileri.

Ni bayi, a pe ara wa ni iru-ọmọ Abrahamu - iru-ọmọ alade rẹ (kii ṣe iru-ọmọ Isaaki), iru-ọmọ alade rẹ, Kristi - a si n ṣiyemeji ileri Rẹ̀. A n jiyan pẹlu rẹ̀, a n sọ wipe ko ri bẹẹ, a si n ṣiyemeji ninu ọkan wa. N ko ro wipe iru-ọmọ Abrahamu ni wa, ti a ba ni iru ero bẹyẹn ninu ọkan wa.

Iru-ọmọ Abrahamu kii ṣiyemeji ohunkohun. O maa n pe ohun ti ko si bi ẹni wipe o wa, nitoriti Ọlọrun sọ bẹẹ. Oun ni Ẹlẹda. O lee mu ki o ri bẹẹ. O ṣe ileri rẹ, o pari niyẹn. Ko ju bẹẹ lọ. Nigbati Ọlọrun ba ti sọ ọ, gbogbo ọrọ naa ti yanju niyẹn.

Ẹ ranti bayi. O n fẹ … ko lee … O sọ fun…

19 Ohun miiran ti O ni ki o ṣe: ki o ya ara rẹ sọtọ kuro lọdọ awọn ara rẹ ati gbogbo awọn eniyan rẹ. Ọlọrun… Lati lee jẹ ki ọkunrin tabi obinrin, ọmọkunrin tabi ọmọbinrin gbọran si i lẹnu, o nilati ya ara rẹ kuro ninu gbogbo aigbagbọ. Bẹẹ ni. Bikoṣe igba ti o ba to ya ara rẹ sọtọ kuro ninu ohun gbogbo ti o lodi si Ọrọ

naa, ki o si gba a gbọ, iwọ… Ọlọrun n beere fun iyasọtọ patapata.

20 Iyatọ nla ni o wa ninu awọn ile-iwe wa loni, ti wọn n ran awọn oniwaasu jade. Wọn… Orişirişi aigbagbọ ni wọn fi n kọ wọn, ati awọn ẹkọ ti ko ba Iwe Mimọ mu, bikoṣe ẹkọ-adamọ lasan ti wọn ṣe funra wọn. Wọn yoo si ran wọn jade pẹlu iru ipilẹ bẹyẹn! Abajọ ti a fi n ran awọn Oswald ati Jack Ruby ati iru awọn bẹẹ jade loni kaakiri orilẹ-ede. Ijọba kosi-Ọlọrun ti gbe orilẹ-ede yii mi nitoriti a ni awọn ile-ẹkọ ẹsin, ati awọn oniwaasu alagbaṣe, dipo awọn ọmọkunrin Ọlọrun ti Ọlọrun ran, ti a ti tun bi, ti a si fi Ẹmi Mimọ kun, ti a fi ina bi, awọn ọmọ Abrahamu ti o gba Ọrọ Ọlọrun gbọ wipe otitọ pọnbele ni, ati wipe kii ṣe ohunkohun bikoṣe otitọ - awọn ẹni takuntakun ti wọn lee duro lori awọn ileri naa loju ohunkohun - ti wọn yoo si doju kọ ọ wipe otitọ ni. Ọrọ Ọlọrun ni! O dara.

21 O wipe, “Ya ara rẹ sọtọ kuro lọdọ awọn ara rẹ, awọn eniyan rẹ - ohun gbogbo - ki o si tẹle mi.” Ọlọrun koi tii yi ọna Rẹ pada. Ọlọrun jẹ Ọlọrun ti ko lee yipada. Ọna ti Ọlọrun gba ṣe ohunkohun lakọkọ, O nilati ṣe e bẹẹ lẹẹkeji. Ẹ ranti, igba ti ẹ ba ri iṣẹ Ọlọrun ni igbakuugba, ti O ba…

Ti eniyan ba sọnu, ti O si gba eniyan la lori ipinnu kan pato ti O ṣe, O nilati maa duro ti ipinnu yẹn titi lae. Ko lee yi i pada. Ṣe ẹ mọ, Oun jẹ ẹni ailopin; awa ni opin. Emi lee mọ si i ni ọla ju bi mo ṣe mọ ni oni lọ. Bẹẹni iwọ naa lee mọ si i ni ọdun ti o n bọ ju bi o ṣe mọ ni ọdun yii lọ. O mọ si i ni ọdun yii ju bi o ṣe mọ ni ọdun ti o kọja lọ. Ṣugbọn Ọlọrun ko ri bẹẹ. O pé. Ailopin ni. Ohun gbogbo ti O ṣe ni o pe. Ko lee ṣe ipinnu kan loni, ki O tun ṣe eyiti o dara ju bẹẹ lọ lọla. Ipinnu Rẹ akọkọ pé. Nitorinaa, o lee fi gbogbo ọkan rẹ sori ohunkohun ti O ba sọ. Otitọ ni.

22 A pe Ọlọrun ni igba kan lati ṣe ipinnu bi a o ṣe gba eniyan la. Ọna ti O gba ṣe e dá lori ẹjẹ alaiṣẹ ti a ta silẹ ni Ọgba Eedẹni. Eniyan ti gbiyanju ohun gbogbo ninu aye lati gba eniyan la yatọ si iyẹn. Wọn ti tẹ awọn ilu do, wọn ti kọ awọn ile-iṣọ, wọn ti ni awọn ijọ ti a ti ọwọ eniyan gbe kalẹ, ati iwe kika, ati ohun gbogbo miiran; ikuna si ni gbogbo rẹ. Ọna kanṣoṣo ni Ọlọrun fi n gba eniyan la: oun naa ni nipasẹ tita ẹjẹ alaiṣẹ silẹ. Ọna kanṣoṣo niyẹn. Ipinnu ti Ọlọrun kọkọ ṣe niyẹn. O si duro lori rẹ titi lae.

Ti Ọlọrun ba wo eniyan kan san lori ipilẹ ti O fi wo o san, O nilati wo ẹlomiran san pẹlu, ti oun naa ba de ipo yẹn. Ti ko ba ṣe bẹẹ, a jẹ wipe O ṣe aṣiṣe nigbati O ṣe ti akọkọ, nigbati O nilati ṣe ipinnu. Ti O ba ṣe ipinnu kan, O nilati duro lori rẹ titi. Ti ko ba ṣe bẹẹ, a jẹ wipe O ṣe ipinnu odi nigbanaa, ṣe ẹ ri i. Tani o si lee sọ wipe Ọlọrun ṣe ipinnu odi? A ko lee sọ bẹẹ. Nitorinaa, Ọlọrun nilati duro lori ipinnu Rẹ titi lae. Nitorinaa, nigbati O ba ṣe ipinnu kan, bi o ṣe ri niyẹn.

23 Nitorinaa, O wipe, “Ya ara rẹ sọtọ kuro lọdọ gbogbo awọn ara rẹ, gbogbo aigbagbọ ti o tẹle ọ wa lati Babiloni.” Igbekalẹ ijọ eniyan akọkọ ni gbogbo aye ni Babiloni, nigbati o ko gbogbo awọn ilu jọ lati maa san owo-ori fun ilu kanṣoṣo - afiwe ni.

Gbogbo awọn ẹkọ-adamọ wọnyi, ati awọn ohun ti ẹ n ri loni… Ti ẹ ba ka iwe “Babiloni Meji” ti Hislop kọ, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ti ẹ si pada si Gẹnẹsisi, ẹ o ri i wipe Gẹnẹsisi ni ibẹrẹ, oun ni irugbin. Ẹ o ri gbogbo awọn ẹkọ-adamọ wọnyi ati awọn nkan miiran nibẹ. Ẹ o ri awọn Farisi agberaga wipe wọn wa lati ibẹ, lati ọdọ obinrin ti o ni gbongbo ti o yani lẹnu nni, ati bẹẹ bẹẹ lọ, titi de ọjọ Jesu. Awọn Farisi ko gbagbọ ninu ẹmi tabi ohunkohun miiran. Wọn si di Jesu lọwọ.

Jesu wipe, “Ẹ fi wọn silẹ. Afọju ti n dari afọju, wọn yoo jọ ṣubu sinu koto ni.” O ṣaa n waasu lọ ni Tirẹ ni, O n mu awọn alaisan lara da, O si n ṣe iṣẹ-iyanu bakannaa. Wọn ko da a duro, nitori Oun ni Ọrọ naa. Ọrọ naa si n tẹsiwaju, laibikita fun ohun ti o n ṣẹlẹ. A ri i wipe awọn nkan wọnni n tẹsiwaju, wọn si wa so eso ni ikẹyin ọjọ wọnyi. Gẹgẹbi Janesi ati Jambresi ṣe tako Mose, bẹẹ naa ni yoo ri.

24 Ni bayi. Iyasọtọ patapata kuro ninu gbogbo aigbagbọ, ẹ si ranti, Abrahamu baba nla, a ko bukun fun-un patapata bikoṣe igba ti o gbọran patapata si ohun ti Ọlọrun ni ki o ṣe. A ko si lee bukun fun awa naa, a ko lee ri ibukun gba, bikoṣe igbati a ba gbọran si ohun ti Ọlọrun ni ki a ṣe.

25 Ohun miiran ti mo fẹ ki ẹ kiyesi nibi yii, ni ori kejila, ni wipe majẹmu naa ko duro lori ohunkohun. Ko si ohun ti o rọ mọ ọ. “Mo ti…”; ki iṣe, “Bi o ba…” Ko si “bi” nibẹ. “Emi ti ṣe e na.” O fun Abrahamu ni majẹmu naa laini ohun ti o rọ mọ ọ.

Ni bayi, ẹ mọ wipe ninu majẹmu ti Adamu, ohun ti o jẹ ni pe “Bi o ko ba fọwọ kan igi yii, nigbanaa, Emi yoo ṣe bayi-bayi. Ṣugbọn bi o ba fọwọ kan-an, njẹ Emi naa yoo ṣe bayi-bayi,” ṣe ẹ ri i. Iyẹn ní ofin kan ti o rọ mọ ọ. Ṣugbọn ninu majẹmu eleyi, “Mo ti ṣe ọ ni baba orilẹ-ede pupọ na.” Oun si ni gbogbo… Ko si ohun ti o rọ mọ ọ. Kiki oore-ọfẹ ni majẹmu naa - oore-ọfẹ patapata ni.

Ohun kanṣoṣo ti wọn nilati ṣe lati jẹ ki majẹmu yii maa tẹsiwaju ni wipe ki wọn duro, ki wọn maa gbe ilẹ naa. Gbogbo ibukun ti o jẹ mọ majẹmu naa si jẹ tiwọn. Ohun kanṣoṣo ti wọn nilati ṣe ni ki wọn duro ni ilẹ naa. A ri i wipe nigbati wọn lọ si Egipti, wọn padanu ibukun wọn; ṣugbọn kii ṣe majẹmu wọn. Majẹmu naa ṣì

wà sibẹ. Wọn padanu ibukun wọn, ṣugbọn wọn ko padanu majẹmu wọn, nitori oore-ọfẹ ni majẹmu wọn, ko duro lori ohunkohun.

26 Ni Ẹksodu, ori kọkandinlogun, Israẹli ṣe… Ọkan ninu awọn aṣiṣe ti o buru ju ti wọn ṣe, ni igba ti wọn kọ oore-ọfẹ, ti wọn si gba ofin. Ẹ wo ohun ti oore-ọfẹ ṣe. Oore-ọfẹ fun wọn ni oludande, o fun wọn ni wolii, pẹlu ọwọn-ina lati fi i han, pẹlu ọrọ ti a fidi rẹ mulẹ, pẹlu ọdọ-aguntan irubọ. Oore-ọfẹ fun wọn ni isọji nla. Oore-ọfẹ mu wọn la a ja, o la Okun Pupa fun wọn, o mu wọn rekọja rẹ, o gba wọn pẹlu iṣẹ-ami ati iṣẹ-ara - gbogbo rẹ nipa oore-ọfẹ ni.

Ṣugbọn wọn n fẹ nkankan lati fun ara wọn ni orukọ nla kan. Njẹ kii ṣe bi awọn eniyan ṣe ri loni naa niyẹn. Nkan kannaa ni. Wọn nilati … eniyan ṣaa n fẹ ki oun naa lọwọ si i nibikan.

Ibi ti Israẹli ti ṣe aṣiṣe nla rẹ niyẹn, nigbati o kọ oore-ọfẹ, ti o si gba ofin dipo rẹ. Ṣugbọn majẹmu ti o ba wọn da jẹ eyiti ko duro lori ohunkohun sibẹ. A ri i wipe bakannaa ni loni.

27 Abrahamu, lẹyin ti a sọ ọrọ yii fun-un, o mu irin-ajo rẹ pọn, o si n lọ. Nikẹyin, o jade, ni ori ikẹtala, o de ibi ẹkunrẹrẹ igbọran si Ọlọrun. A ri i ni ori ikẹtala wipe Lọọti… Ṣaaju, o mu baba rẹ dani. Baba naa si n jẹ idiwọ ni gbogbo igba. O gbiyanju lati ko ọpọlọpọ eniyan dani pẹlu rẹ. Nigbati o ba ṣe bẹẹ, ibi ti iwọ yoo ti ni wahala niyẹn. Ọlọrun wipe, "Ya ara rẹ sọtọ."

"O dara, jẹ ki n sọ fun ọ. Wọn ko gbagbọ gan-an, ṣugbọn…" Kuro nibẹ nigbanaa. Ohun kanṣoṣo ti o nilati ṣe niyẹn. Ṣaa takete si i.

Nikẹyin, wọn nilati sin baba arugbo naa. Lẹyin eyi, Lọọti naa di wahala fun-un. A ri i wipe o bẹrẹ si kùn, awọn mẹjẹeji si ni ọrọ̀, wọn ni ohun pupọ. A wa ri i wipe, Lọọti bẹrẹ asọ̀ - awọn darandaran rẹ ati awọn darandaran Abrahamu.

28 A ri i wipe ko … Ọlọrun koi tii ri ẹkunrẹrẹ isotitọ ninu Abrahamu, lati gbọran si ohun ti O ni ki o ṣe: lati ya ara rẹ sọtọ patapata kuro lọdọ awọn ará rẹ, kuro lọdọ awọn eniyan rẹ, ati lati sin-in. A ri iyẹn, wipe Ọlọrun n ba Abrahamu sọrọ nibi pẹpẹ, O sọ ohun ti o yẹ ki o ṣe fun-un…

Nikẹyin, Lọọti, nigbati o de … nigbati ọrọ ṣẹlẹ laarin Abrahamu ati… Lọọti jẹ ọmọ Harani arakunrin rẹ, (iyẹn ni ọmọ aburo rẹ), nikẹyin, o wipe, "Arakunrin ni wa. A ko gbọdọ maa ba ara wa ja. Bi iwọ ba lọ si ila-oorun, emi yoo lọ si iwọ-oorun. Bi o ba si lọ si iwọ-oorun, emi yoo lọ si ila-oorun. Ya ara rẹ sọtọ, a ki yoo si… Ilẹ pọ fun gbogbo wa. Iwọ maa lọ … yan ibi ti o ba wu ọ." Ẹmi Kristẹni tootọ niyẹn ninu Abrahamu - o fun ọta ni anfaani lati kọkọ yan. O fun-un ni anfaani lati yan ọna ti yoo rin.

29 Lọọti, bi ọpọlọpọ eniyan loni, o ri anfaani naa. O ro wipe ti oun ba lee kuro ninu ofin ti o de oun yẹn, oun yoo lee pa owo diẹ si i. Oun lee di olokiki. Nitorinaa, o wo iha Sodomu, koriko ibẹ tutu minimini, ilu nla si ni, pẹlu ile-iṣẹ iyọ nla ati bẹẹ bẹẹ lọ. Wọn n ko awọn ọja lọ si okeere lati ibẹ.

Yatọ si iyẹn, o tun kun fun awọn obinrin aye pẹlu ọda Jesebeeli wọn, ati ohun gbogbo - pẹlu igbadun nla. Iyawo rẹ naa ro bẹẹ. Nitori a ri i wipe lẹyin ti o di alaga ni ilu yẹn, oun naa … oun naa fẹran ọna igbe-aye awọn eniyan wọnyẹn. Ohun kan ti o si nilati ṣe niyẹn, ni ki o dara pọ mọ nkankan. Ọlọrun fẹ ki o ya ara rẹ sọtọ, ki o rin jinna si awọn nkan wọnni tobẹẹ ti iwọ ki yoo ri wọn mọ rara. Ohun kanṣoṣo ni iwọ yoo maa ri, iyẹn ni Oun ati ohun ti O ṣe ileri.

Ṣugbọn Iyaafin Lọọti, o dabi ẹni wipe o fẹran rẹ, ko si iyemeji wipe o sọ pe, "Olufẹ mi, mo lọ si… Iwọ wo bi awọn obinrin ibẹyẹn ṣe n mura. Wo awọn ọmọbinrin wọnyẹn. Wo bi awọn ọmọbinrin tiwa ṣe n mura. Ṣe o ko ro wipe wọn laju ju wa lọ?

Akiika! Njẹ a ko ti pada sinu Sodomu miran bayi, emi ko mọ.

30 Ṣugbọn a ri i wipe Abrahamu duro ti ileri naa. A ri i bi o ṣe n tẹsiwaju, ni… Bi wọn ṣe yago fun ara wọn ti Lọọti si… Abrahamu gba ilẹ ti o ti ṣá, ibi kekere kan ni, o duro si ibi ti ko ti si ounjẹ pupọ fun awọn ẹranko rẹ lati jẹ. Ṣugbọn o ṣetan lati rin ọna naa, nitori Ọlọrun ni o fi si ilẹ yẹn, ibi ti o si fẹ duro si niyẹn, o ṣetan lati gba a.

Nigbati o gbọran si Ọlọrun lẹnu lẹkunrẹrẹ, nigbati o gbọran si Ọlọrun lẹnu de oju ami, lati ya ara rẹ sọtọ patapata, igba naa ni Oluwa fi ara han-an. Ki o to ṣe iyẹn, Oluwa ta kete si Abrahamu. Ṣugbọn nigbati o gbọran lẹkunrẹrẹ, nigbanaa ni Ọlọrun fi ara han-an, O si wipe, "Abrahamu, gbe oju rẹ soke. Wo ila-oorun, wo iwọ-oorun, wo ariwa, wo guusu. Tirẹ ni gbogbo rẹ." Amin!

Mo fẹran iyẹn.

31 Bi o ṣe ri naa niyẹn nigbati a gba mi la. Mo ti maa n gbọ wipe titobi ni Ọlọrun. Njẹ ẹ mọ, nigbati a gba mi

la, ẹnikan wipe, “Ni bayi, gbogbo ohun ti o nilati ṣe ni ki o darapọ mọ ijọ kan, ki o si fi orukọ rẹ sinu iwe ijọ yii, ninu ijọ Onitẹbọmi. Gbogbo ohun ti o nilati ṣe niyẹn.”

Ṣugbọn njẹ ẹ mọ, lọjọ kan, mo ri i wipe mo jẹ ajogun ohun kan. Mo si fẹ wo o, ki n ri ohun ti mo ni. Ẹ mọ wipe bi mo ṣe ri niyẹn. Bii agbo-ile nla kan ni - iwọ ni o ni i, ohun gbogbo ti o wa nibẹ, tirẹ ni. O ko mọ ohun ti o ni ayafi ti o ba lọ wo inu Bibeli, lati ri awọn ileri naa. Amin. Wọn yoo mu ọ jinna si ibẹ, ti wọn ba lee ṣe e. Ṣugbọn tirẹ ni gbogbo rẹ.

Gbogbo ileri naa wa fun Abrahamu, ati fun iru-ọmọ rẹ lẹyin rẹ. Amin! Gbogbo ileri atọrunwa ninu Ọrọ naa jẹ ti Abrahamu, ati iru-ọmọ rẹ. Iwọ si jẹ ajogun rẹ - ajogun! Kai! Mo fẹ lati wo o, ki n lee mọ ohun ti mo ni. Ti ẹnikan ba fun mi ni nkankan, maa fẹ lati wo o finifini. Mo si fẹ lati wo inu Bibeli, ki n lee mọ ohun ti o jẹ temi. Gbogbo iru-ọmọ Abrahamu ni o nilati ṣe bẹẹ.

Nigbati o ba di atunbi, ti a fi Ẹmi Ọlọrun kun ọ, ti Ẹmi Mimọ si wa ninu rẹ, o jẹ ajogun gbogbo awọn ileri wọnyẹn.

32 Ṣe ẹ mọ, o dabi igba ti mo wipe - agbo-ile nla kan. A baptiisi wa sinu agbo-ile yẹn. Nipa Ẹmi kan ni a baptiisi gbogbo wa sinu ara kan. Kristi ni ara naa, eyiti iṣe iru-ọmọ alade ti Abrahamu, a si jẹ ajogun ohun gbogbo ti o wa ninu rẹ. Amin!

Ohun gbogbo ti o wa ninu Ọlọrun, Ọlọrun tu u da sinu Kristi. Ohun gbogbo ti o wa ninu Kristi, o tu u da sinu onigbagbọ. Ọlọrun ní oke wa, Ọlọrun pẹlu wa, ati Ọlọrun ninu wa. Ohun gbogbo, gbogbo ileri inu iwe naa, tirẹ ni, ti o ba lee gba a gbọ - ti o ba ni igbagbọ ti o to lati gba a, ki o si gba a gbọ.

33 Ṣe ẹ mọ, mo wo ayika. Ti mo ba ri ohun kan ti o dabi ẹni wipe o ga diẹ, emi yoo fẹ mọ ohun ti o wa ninu rẹ. Emi yoo gbe akasọ, n o maa ti i kaakiri, n o si maa gun-un titi ti n o fi de oke rẹ. Bi o ṣe ri pẹlu ileri inu Bibeli niyẹn. Bi ohunkohun ba dabi ẹni wipe o ru mi loju diẹ, emi yoo maa gbadura titi ti n o fi de ibẹ. Ko ju bẹẹ lọ. Bi a ti ṣe e niyẹn. Ṣaa maa gbadura, maa duro, maa goke lọ - maa gbagbọ titi ti iwọ yoo fi jogun rẹ. O ni ileri kan fun-un, o si ni ẹtọ si i, “Beere, iwọ yoo si ri gba. Nitori ohun gbogbo lo ṣee ṣe fun awọn ti o gbagbọ.”

A ri i wipe Abrahamu rin ilẹ naa ja. Ọlọrun sọ fun, wipe, “Rin ilẹ naa ja. Wo gbogbo rẹ. Ohun gbogbo ti o wa nibi yii, tirẹ ni. Tirẹ ni gbogbo rẹ laiṣẹku ẹyọkan. Tirẹ ni gbogbo rẹ.”

34 A tun ri i ni ori ikẹrinla iwe Ẹksodu bayi, tabi ori kẹrinla iwe Gẹnẹsisi (ẹ jọwọ o), ni ori ikẹrinla iwe Gẹnẹsisi, Abrahamu ati Lọọti ti pinya, Lọọti si pada bọ sinu wahala nikẹyin. Bi iwọ naa ṣe maa n ṣe niyẹn. Nigbati o ba ya ara rẹ sọtọ kuro lọdọ awọn onigbagbọ, o ti fẹ bọ sinu wahala niyẹn.

A ri i wipe awọn ọba naa ti fọwọsowọpọ, wọn si gbe ogun wa. Wọn ṣokalẹ wa, wọn si ko Sodomu, wọn ko Gomora, wọn ko gbogbo awọn ọba, wọn gba gbogbo papa ati afonifoji, ati ohun gbogbo. Wọn mu Lọọti. Awọn eniyan diẹ ni o sa asala lọ sori oke. Nigbati wọn ṣe bẹẹ, ẹnikan ti o sa asala wa sọ fun Abrahamu, ti o jẹ Heberu. O ni, “Sodomu ti fo, ati Gomora, wọn ti ko awọn ọba wọn ati ohun gbogbo, wọn ti ko gbogbo awọn eniyan, ati ounjẹ wọn, ati ohun gbogbo ti wọn ni. Wọn mu Lọọti ati iyawo rẹ̀, ati awọn ọmọbinrin rẹ̀ - gbogbo awọn obinrin - wọn si ti ko wọn lọ.”

35 Ni bayi, Abrahamu - ẹ kiyesi ẹmi Kristẹni yii, ti o wa arakunrin rẹ lọ. Abrahamu, pẹlu Lọọti ti o ti pada ṣẹyin, o ti pada… Sibẹ, Abrahamu fẹran rẹ. O ṣaa n wa a lọ ni, bii Jesu ni igba ijọ Laodikea. Sibẹ, wọn lee jade kuro ninu ijọ, O si wa ni ita, O n kan ilẹkun, O n gbiyanju lati wọle pada. Ti ẹnikan ba ṣaa lee ṣi ilẹkun, ki O lee wọle… Ẹmi Abrahamu niyẹn, ti o n wa arakunrin rẹ ti o ti ṣubu lọ.

O wa a lọ. O ko awọn ọmọ-ọdọ rẹ ti o jẹ ọọdunrun, o fun wọn ni ohun ija. O si pade rẹ ni Dani. Iyẹn ni ẹyin odi Palẹstini. O pade rẹ nibẹ, o si pin awọn eniyan rẹ si ọtọọtọ ni oru, o le wọn, o baa wọn ọmọ ogun naa ja, o si bori awọn ọba naa, o pa wọn, o si da ohun gbogbo ti wọn ko lọ pada.

36 Ẹ kiyesi i, nigbati o pada de, apẹẹrẹ ti o dara ni a ri nibi yii. Idi niyẹn ti mo fi fẹ ṣe afiwe rẹ diẹ, ki a lee loye … ki n to de ibi akori mi ti o jẹ “Jehofa-jire.” Ti ẹ ba kiyesi i, Abrahamu da ohun gbogbo ti o ti sọnu pada - arakunrin rẹ ti o ti ṣako lọ, ati awọn ọmọ rẹ… Bi o ṣe n ko wọn pada bọ, awọn ọba wa pade rẹ. Melkisedeki naa jade wa, ẹniti iṣe ọba Salẹmu, ọba alaafia, ọba ododo, ọba Jẹrusalẹmu, laini baba, laini iya, laini ibẹrẹ ọjọ, laini opin igba. Melkisedeki pade rẹ nibi pipa… bi o ṣe n ti ibi pipa awọn ọba bọ, ẹniti o…

Abrahamu baba nla (Heberu 7) pade ọkunrin yii, o si san idamẹwa, idamẹwa. Ẹni nla ni ọkunrin yii nilati jẹ. Tani ẹ ro wipe o jẹ? Ko ni baba. Ko ni iya. Ko ni ibẹrẹ. Ẹni yoowu ti O jẹ, O n bẹ laaye sibẹ. Ko fi igba kankan ni opin - ọba Salẹmu, ọba alaafia. Ah, tani ẹni nla yii?

37 Ẹ kiyesi afiwe ti a ri nibi yii. Lẹyin ti ogun pari - lẹyin ti onigbagbọ tootọ ti ba ọta ja, ti o kọlu ọta, ti o si

gbiyanju lati mu arakunrin rẹ - lẹyin ti iru-ọmọ Abrahamu tootọ ti mu arakunrin rẹ ti o ṣako lọ pada, Melkisedeki jade wá, o si fun-un ni waini ati akara - idapọ - o fun-un ni idapọ lẹyin ti ogun pari. O fun-un ni idapọ lẹyin ogun jija.

Afiwe ti o dara niyẹn nipa igba ti ogun ba pari lori ilẹ-aye nihin. A ti ṣẹgun. Jesu wipe wọn yoo jẹẹ ni ọtun ninu ijọba Baba. Lẹyin ti a ti mu aṣako pada wale, ohun akọkọ ti a o ṣe nigbati a ba wọle lọ lẹyin ogun, ni ki a joko sibi tabili ni ijọba Ọlọrun. Nibẹ, awọn ti wọn ti jà, ti wọn si ti joko, ti wọn ti ṣẹgun, ni a o fi ododo Kristi wọ ni aṣọ. Lẹyinnaa, wọn yoo jẹ akara ati waini ninu ijọba Baba, ni odikeji lọhun. Aworan nla ni eyi, wipe Abrahamu jade lọ gba Lọọti, o si mu u pada wa.

38 Ni bayi. A ri i ni ori kẹẹdogun, a ri nkankan ti o ṣe koko nibẹ. Mo fẹran eleyi gan-an ni. Bi a ti mọ ẹniti Abrahamu jẹ, Abrahamu ati iru-ọmọ rẹ lẹyin rẹ, a ri i nibi yii wipe lẹyin ti Abrahamu ti ṣe awọn nkan nla wọnyi - ni gbigba Ọlọrun gbọ, didi ileri mu, yiya ara rẹ sọtọ, ti o si n tẹle gbogbo aṣẹ Oluwa ni gbogbo ọna - a ri i wipe Ọlọrun fi ara han-an nibi pẹpẹ. Abrahamu si beere ibeere kan lọwọ Rẹ, o ni, “Wayi o, tani arole mi bikoṣe Eliasari ara Damasku yii? O ṣe ileri iru-ọmọ fun mi. Mo si fẹ ki O ṣe nkankan. Mo fẹ ki O fidi ileri yii mulẹ fun mi.”

39 Ọlọrun si wipe Oun yoo fidi rẹ mulẹ fun Abrahamu - fifi idi majẹmu ti O ti ṣe mulẹ laarin Oun ati Abrahamu. Bayi, yoo fun-un ni ami wipe yoo jẹ otitọ; wipe bi o tilẹ di arugbo (o ti fẹrẹ pe ọmọ ọdun marundinlaadọrun bayi), ṣugbọn sibẹ, O fẹ fihan fun-un nipa ami kan, wipe Oun yoo pa majẹmu naa mọ.

Inu mi dun pupọ wipe Ọlọrun maa n fun wa ni ami, nitori O… O yẹ ki a mọ, loni, wipe ni wakati ti a n gbe inu rẹ bayi, ami kan yẹ ki o wa lori ilẹ aye ni akoko yii. A nilati maa foju sọna fun ami kan. Ọlọrun kii ṣe ohunkohun lai jẹ wipe O ba fun awọn eniyan ni ami ati ikilọ. Ohùn kan si maa n tẹle ami tootọ. Ohùn naa si maa n jẹ eyiti o ba Iwe Mimọ mu.

40 Ni bayi, O fẹ fidi majẹmu naa mulẹ fun Abrahamu, tabi Abramu, bẹẹni. O si wipe, “Mu ẹgbọrọ maaluu kan [ẹ ranti, abo maaluu niyẹn], ki o si mu abo ewurẹ kan, ọlọdun mẹta.” Ọkọọkan wọn gbọdọ jẹ ọdun mẹta. E kiyesi i, maaluu ọlọdun mẹta (abo), ewurẹ ọlọdun mẹta (abo) ati agbo kan (ako), ọkọọkan jẹ ọlọdun mẹta. Mẹta si ni wọn. Abo mẹta … abo meji ati akọ kan, ṣe ẹ ri i. Ẹbọ mimọ ọlọdun mẹta (abo maaluu kan), abo ewurẹ ọlọdun mẹta, lẹyinnaa, àgbò kan.

41 Ti ẹ ba kiyesi i, gbogbo rẹ jẹ ami.

Ko yẹ ki n kọni ni ẹkọ lati ori pẹpẹ nibi yii, o si da mi loju wipe iyẹn sunmọ ọ tobẹẹ ti o fi lee ye yin.

Ẹ kiyesi i. O mu ẹyẹ meji - ẹyẹle kan, ati adaba kan - ẹbi kannaa ni wọn, ẹyẹle ati adaba. Ni bayi, o la ewurẹ … aguntan yẹn si meji… O la agbo ati ewurẹ ati awọn ti o ku - o pin wọn si meji, o la wọn si meji, o si ko wọn silẹ. Ṣugbọn awọn adaba, o … ati ẹyẹle ni kò là. Iyẹn ni… Ẹnikẹni ti o ba mọ Iwe Mimọ mọ wipe iwosan atọrunwa niyẹn, ṣe o ye yin. O wa ninu majẹmu mejeeji. A si ri i wipe o ko wọn silẹ ni…

Iwosan maa n wa nipa igbagbọ ninu ẹjẹ ti a ta silẹ, ni gbogbo igba. Majẹmu atijọ naa si ni iwosan atọrunwa. Melomelo ni majẹmu titun ni i, ṣe ẹ ri i? Ti majẹmu atijọ ba ni i, titun nkọ - nigbati o jẹ wipe majẹmu ti o dara ju ni, ti o n sọ ohun ti o tobi, ti o ga ju, ti o tobi ju, ti o dara ju - majẹmu titun naa.

42 A ri i nibi yii, wipe Abrahamu, nigbati o ṣe eyi, ẹ kiyesi ohun ti o ṣẹlẹ. Koko kan ti o ṣe pataki niyi o (emi ko fẹ ki ẹ padanu rẹ): ifidimulẹ majẹmu naa niyẹn. Iyẹn ni wipe, ileri ni wipe, “Mo jẹ olootọ si ohun ti mo n ṣe, tabi ohun ti mo sọ wipe emi yoo ṣe,” Ọlọrun n fidi rẹ mulẹ fun Abrahamu. O mu awọn ẹbọ wọnni, o pa wọn, o si fi wọn ko ara wọn bi o ṣe ko wọn kalẹ. O n le awọn ẹyẹ kuro nibẹ, ki awọn ẹyẹ ma baa ba le ẹran aṣẹṣẹpa naa, titi ti oorun fi wọ ni irọlẹ.

43 Nigbati oorun wọ, tabi ti o n wọ, O fihan fun Abrahamu, ohun ti Oun yoo ṣe ni ọjọ iwaju, ohun ti yoo ṣẹlẹ. Ẹ kiyesi i, O sọ fun Abrahamu… Ohun ti o kọkọ ri ni okunkun ti o bani lẹru, ti o bo o mọlẹ. Ṣaaju, oorun ijika kun-un. Oorun yẹn jẹ apẹẹrẹ iku fun gbogbo eniyan. Gbogbo eniyan ni o nilati ku. Iku fun gbogbo eniyan - oorun yẹn kun-un. Ṣaaju iyẹn, okunkun biribiri bo o mọlẹ. Lẹyinna, ina ileru kan kọja. Lẹyinnaa, imọlẹ kekere kan kọja laarin majẹmu naa, o kọja laarin ẹbọ naa - o pin-in si meji.

Kini iyẹn tumọ si? O tumọ si wipe gbogbo eniyan ni o nilati ku, lẹyin iyẹn, wọn yẹ lati lọ si ọrun apaadi. Bẹẹ ni, ninu okunkun, okunkun lode, pẹlu ipinya kuro lọdọ Ọlọrun. Ṣugbọn imọlẹ wọle wa, o si gba aarin wọn kọja, o pin awọn ẹbọ naa. Ti o ba ye yin, wipe majẹmu naa…

44 Bii awa Amẹrika, bawo ni a ṣe maa n dá majẹmu? Ohun akọkọ ti a maa n ṣe, a o wipe… Ti a ba fẹ da majẹmu okòwò, tabi nkankan. A maa n saaba jade lọ jẹun, a o joko, a o sọrọ fun igba diẹ, lẹyinnaa, a o dabaa, lẹyin eyi, a o bọ ara wa lọwọ. A o wipe, “Jẹ ki a bọwọ lori rẹ̀.” Majẹmu tiwa niyẹn, ileri wa niyẹn.

Ni Japan, ẹ mọ bi wọn ṣe maa n dá majẹmu ni Japan? Awọn naa ni ohun ti wọn yoo jẹ. Lẹyin eyi, wọn yoo gbe kolobo iyọ kekere kan, wọn yoo si da iyọ si ara wọn lara. Ifidimulẹ majẹmu naa niyẹn. Awa yoo bọ ọwọ, a o si wipe, “A ti ṣe edidi rẹ, ọmọ. Mo gba a gbọ. Emi yoo duro ti ọ. Ileri ni.” Awọn ara Japan … ni Japan, wọn yoo wọn iyọ si ara wọn lara. “A ti ṣe edidi rẹ, ọrẹ. O ti pari. Opin gbogbo ariyanjiyan niyẹn.” Wọn ti dá majẹmu niyẹn, wọn fidi rẹ mulẹ nipa wiwọn iyọ si ara wọn lara.

45 Ṣugbọn ni atijọ … ni atijọ, bi wọn ṣe maa n dá majẹmu niyi. A o kọ adehun wa silẹ. A o si mu adehun naa - a o kọ ọ silẹ - a o si pa ẹranko kan (ẹbọ), a o pin-in si meji, a o si gbe e kalẹ bii ti àkókò Abrahamu, lẹyin eyi, a o duro si aarinmeji majẹmu yii, iwọ ati emi, a o jẹ́ ẹ̀jẹ́ fun Ọlọrun. “Ti a ba kuna lati pa majẹmu yii mọ, jẹ ki a dabi oku ẹranko ti a fi rubọ yii, eyiti o ku ni ipo awa mẹjẹeji. Jẹ ki ẹjẹ ẹbọ yẹn dahun fun wa. Ki a ku iru iku kannaa ti a ba kuna lati pa majẹmu naa mọ.” A o kọ ọ silẹ, a o kọ ọ sinu iwe kan, bẹyẹn. A o ya a si meji, bẹyẹn. Iwọ yoo mu ilaji, emi naa yoo mu ilaji.

Ni bayi, ṣe ẹ mọ, o ko lee ṣe ẹ̀dà rẹ rara, paapaa julọ ti a ba kọ ọ sori awọ aguntan. O ko lee ṣe ẹ̀dà rẹ rara. Eyi nilati ba iyẹn mu rẹ́gí, lati mu ki o ri bẹẹ. Lẹyinnaa, nigbati a ba pade… Emi yoo mu apakan, iwo naa yoo mu apa keji. Lẹyinnaa, nigbati a ba pade, ti a si fẹ dá majẹmu yii, ti a fẹ san ẹ̀jẹ́ wa, iwe temi gbọdọ ba iwe tirẹ mu. Nitoripe iwọ ni o wa pẹlu mi ninu majẹmu naa.

46 Ohun ti Ọlọrun fihan wipe Oun n ṣe nibẹyẹn ni wipe Ọlọrun funra Rẹ yoo sọkalẹ wa di ẹran-ara, Oun yoo si wa ninu majẹmu naa. Ọlọrun mu Kristi (Ẹmi naa, Ọlọrun, Jehofa) mu Kristi ni … lori agbelebu, O fa a ya si meji. O fa ọkan rẹ yọ, o si gbe e lọ si ọrun, O fi ara Rẹ sinu iboji, O si gbe ara naa lọ soke ni owurọ ọjọ ajinde, O si fi Ẹmi ti o wa ninu Rẹ ranṣẹ pada lati wa ninu ijọ. Ifidimulẹ kannaa ni. Ni ikẹyin ọjọ yii, Jesu Kristi ọkannaa lana, loni, ati titi lae - majẹmu kannaa ni - oun ni o nilati wa ninu awọn eniyan.

Bawo ni ẹ ṣe fẹ ri i gba nipa iwe kika? Bawo ni ẹ ṣe fẹ ri i gba ni ọna miiran, yatọ si ifidimulẹ Jesu Kristi ti o jinde, ti o si wa laaye, ẹniti a ji dide kuro ninu oku, ti o si joko lọwọ ọtun Ọlanla loke ni aṣalẹ yii; Ẹmi kannaa ti o wa ninu Rẹ ni o wa ninu iru-ọmọ alade Abrahamu ni ikẹyin ọjọ wọnyi, o n fidi rẹ mulẹ wipe ọkannaa ni lana, loni, ati titi lae. Amin! O mu inu ẹni dun, tabi bẹẹkọ?

Majẹmu naa niyẹn. “Emi yoo kọ majẹmu mi sinu ọkan wọn.” Jesu wipe, “Iṣẹ ti mo ṣe ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu.”

47 Bi a ṣe n bọ wa si Sodomu ni iṣẹju melo kan, ẹ kiyesi bi o ṣe ri, bi o ṣe ṣẹlẹ nibẹ, bi ileri naa ṣe ri fun ikẹyin ọjọ niyẹn, ati ohun ti Oun yoo ṣe. O n fidi rẹ mulẹ, O n fihan wipe O la ara Jesu si meji, O mu Ẹmi, O gbe ara naa lọ si ọwọ ọtun itẹ Ọlọrun, O si fi apa keji ranṣẹ - apa ibi ti o mu jade, ani Ẹmi - sinu wa (eyiti a pe ni Ẹmi Mimọ). Ìyè ti o wa ninu Kristi naa ni o wa ninu rẹ. Iyẹn ni o fihan wipe Olurapada rẹ ni iṣe. O ti sọ ọ di ọmọ Ọlọrun. Bayi, a jẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun, pẹlu Ẹmi Kristi. “Iṣẹ ti mo ṣe ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu. Ju iwọnyi lọ ni ẹyin o ṣe; nitori emi n lọ sọdọ Baba.” Amin.

48 Ẹmi ti o wa ninu Rẹ, wa ninu rẹ, iye ainipẹkun ni. Oun ni olufunni ni iye ainipẹkun. Oun ni Olurapada, lati da pada, eyiti o ṣubu ni igba iṣubu iran eniyan, lati da wọn pada sọdọ Ọlọrun. Ẹmi ti o wa ninu Kristi ni o wa ninu rẹ. Bi ẹmi ọdaran ba wa ninu mi, emi yoo ni ibọn. Bi ẹmi ayaworan ba wa ninu mi, emi yoo maa ya awọn aworan. Bi Ẹmi Kristi ba wa ninu mi, emi yoo maa ṣe iṣẹ Kristi. Amin! Bẹẹ ni.

Ìyè ti o wa ninu Rẹ̀ ni o wa ninu rẹ.

49 Mu iye ohunkohun sinu ohun miiran… Ti o ba lee mu iye eso elégéde sinu ẹgusi, yoo maa so eso elégédé ni. Bẹẹ ni. Ti o ba mu iye inu igi eso peach, ki o fi sinu igi eso pear, yoo maa so eso peach ni, nitori iye ti o wa ninu igi ni yoo fi ohun ti o jẹ han. Bi iru-ọmọ alade naa ṣe… Nipasẹ Isaaki ni ọmọ ara naa ṣe wá, awọn ti wọn kọ̀ ọ. Lori agbelebu, lati ọdọ Efraimu si ọdọ Manasse, a paarọ rẹ - ibukun naa - lati ọwọ ọtun si ọwọ osi (tabi lati ọwọ osi ti o jẹ ti ọwọ osi, lati ọdọ aburo si ọdọ ẹgbọn) nibẹyẹn; o si yi gbogbo rẹ pada lati ọdọ Isaaki ti ara - eyiti o kọ Kristi - ninu ijọ ti ara loni, ti o si n kọ ọ sibẹ.

50 Ṣugbọn iru-ọmọ alade ti ẹmi (Ọlọrun) ti o gbagbọ, iru-ọmọ alade Abrahamu ti o gba gbogbo Ọrọ Ọlọrun gbọ, wọn ni ifidimulẹ Jesu Kristi ti o wa laaye ninu wọn. Akiika!

Bakannaa ni. Gbogbo ijọ gbọdọ jẹ ibatan. Nigbati a ṣe afiwe rẹ ninu iru ti ara… Ẹ wo o, Isaaki ati Rebeka, ibatan ni wọn jẹ - ẹ̀jẹ̀ kannaa ni wọn - baba kannaa, ṣe ẹ ri i. Tẹgbọn-taburo ni awọn baba wọn - iyẹn ni wọn fi jẹ ẹjẹ kannaa, iyawo ati ọkọ-iyawo. Ninu Adamu ati Eefa, Adamu ni gbogbo rẹ lati ilẹ wa. Ọlọrun mu egungun kan lati iha rẹ, o fi da obinrin. O si mu ẹmi abo kuro ninu Adamu, O fi sinu obinrin naa.

51 Nitorinaa, nigbati obinrin ba n ṣe bii ọkunrin, nkankan wa … idibajẹ kan ti wa nibikan. Nigbati ọkunrin naa ba si fẹ dabi obinrin, nkankan ti ṣọwọ odi nibikan. Ọlọrun da ọkunrin, O si mura fun-un bii ọkunrin, ati obinrin bii obinrin. O fẹ ki wọn wa bẹẹ titi. Amin. Nigbati ẹ ba ri wọn ti wọn n ṣe nkan miiran, nkankan ti kuna. O ti dibajẹ. Gbogbo rẹ ti wa di idibajẹ. Bẹẹ gan-an ni. Gbogbo iran eniyan, gbogbo iran, o ti… Gbogbo rẹ ti di

egbo kikẹ, gẹgẹbi Bibeli ti sọ. Ko tilẹ si ohun ti o ye kooro nibikibi mọ. Ẹ mọ wipe otitọ niyẹn.

O ko lee ri i laarin awọn… Lọ soju titi, o nira lati ri ọkunrin gidi - ọkunrin-bi-obinrin ni gbogbo awọn ti mo n ri kaakiri. Awọn obinrin nkọ, wọn n wọ ṣokoto, wọn n ge irun wọn, wọn n kun ọda si ete wọn, wọn n mu siga, wọn n gbiyanju lati di ọkunrin. Kini ẹ fẹ di ọkunrin fun? Obinrin lo yẹ ki ẹ jẹ.

Mo ri ami kan ti o wipe, “Tabili fun awọn Obinrin” ni ile-ọti kan. Mo ni, “O ko lee ni onibara. Obinrin gidi ko ni lọ si iru ibẹyẹn.” Rara, sà. Obinrin gidi ki yoo ṣe bẹẹ. Obinrin lasan lee ṣe bẹẹ; ṣugbọn kii ṣe obinrin gidi. Ko ni lọ si iru ibẹyẹn. Ṣugbọn bi o ṣe ri niyẹn.

52 Ọlọrun ṣe ipinya, o ge… Ara naa, iyawo Kristi, nilati pada wa si akọkọ… Eefa jẹ… Kini Eefa jẹ? Ọkannaa ni oun ati Adamu. A pe wọn ni “Adamu.” Ẹmi ni wọn. Nigbati O kọkọ da eniyan, O da wọn ni aworan ara Rẹ. Ẹmi si ni Ọlọrun. “Ni aworan Ọlọrun ni O da a. Ati akọ ati abo ni O da wọn.” O jẹ…

Sibẹ, ko si eniyan lati ro ilẹ. Lẹyin eyi, Ọlọrun fi erupẹ ilẹ mọ eniyan, o si fi ẹmi mejeeji yii sinu rẹ. Adamu akọkọ niyẹn.

53 Nigbati o ya Eefa kuro lara Adamu, Eefa ṣubu nipa aigbagbọ ninu Ọrọ naa. Bẹẹni.

Ibi ti ijọ ti kuna loni niyẹn - aigba Ọrọ naa gbọ. Ṣugbọn nibi yii, si iru-ọmọ alade ti a ti pè, ti a ti yan tẹlẹ si iye ainipẹkun, iru-ọmọ alade ti Abrahamu - wọn gba Ọrọ yẹn gbọ. Emi ko bikita ohun ti o lee ṣẹlẹ, bi wọn ṣe fi wọn ṣe ẹlẹya to, ohunkohun ti ẹnikẹni sọ, iyẹn tabi omiran, a ti yan wọn tẹlẹ si iye ainipẹkun. Yoo si pada sibẹ. Oun ati olufẹ rẹ, Kristi, ọkan ni wọn.

Iye naa, Ẹmi ti o wa ninu Kristi, ni o wa ninu ijọ. Majẹmu ainipẹkun naa niyẹn. Ọlọrun mu Ẹmi Kristi, O fa yọ kuro ninu ẹbọ naa ni Kalfari, O si mu Ẹmi naa, O gbe ara naa lọ soke, O gbe e si ọwọ ọtun itẹ Ọla-nla Ọlọrun ni oke ọrun - ohun ti o n ṣakoso ohun gbogbo ti o wa ni ọrun niyẹn. Ẹmi ti o wa ninu Rẹ̀ si pada wá. Ẹmi kannaa - kii ṣe ẹmi miiran - Ẹmi kannaa ba le e lati fidi majẹmu naa mulẹ fun iru-ọmọ alade naa

54 ni ikẹyin ọjọ. O yẹ ki a ri i, ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ.

Ki a to lee gba iyawo Kristi lọ soke, iṣẹ-iriju iwaasu kan nilati wa ti yoo ba iyẹn mu gan-an. Amin! Inu mi dun lati sọ ni aṣalẹ yii wipe mo mọ pe otitọ niyẹn. Amin! O ba ara mu, O fidi majẹmu naa mulẹ - O fidi rẹ mulẹ nibẹyẹn; O fi ohun ti Oun yoo ṣe han-an, nipa fifi idi majẹmu naa mulẹ. Gbogbo awọn ti o mọ Bibeli mọ wipe ohun ti O fidi rẹ mulẹ niyẹn: majẹmu fun Abrahamu.

Kini O n ṣe? O n fihan nipa ojiji, ohun ti Oun yoo ṣe pẹlu awọn ẹbọ wọnyi. Ni bayi, ilẹ ti n ṣu. N ki yoo ni akoko lati pin awọn ẹbọ wọnyi si wẹwẹ. Boya n o ṣe iyẹn ni alẹ ọla (ṣugbọn ẹ kiyesi i), fi ohun ti wọn … ohun ti awọn ẹbọ wọnyi tumọ si han. Ṣugbọn ẹ wo o, O fidi rẹ mulẹ, O n fihan wipe ni ikẹyin ọjọ…

55 Ẹnikẹni ti o ba ka itan aye atijọ mọ wipe bi wọn ti maa n dá majẹmu niyẹn. Wọn yoo kọ iwe, wọn yoo si ya a si meji, wọn yoo fun ẹni kinni ni apa kan, wọn yoo si fun ẹnikeji ni apa keji. Wọn nilati pada wa fun ẹbọ, wọn yoo ṣe irubọ. Ohun ti Abrahamu ṣe si … ni Gerari, ati bẹẹ bẹẹ lọ, wọn ṣe adehun, wọn ya a si meji. Ọlọrun ṣe nkan kannaa, O n fihan nibẹ, wipe ohun ti Oun yoo ṣe si…

56 Ibeere naa ni wipe, “Iru-ọmọ ti O ṣe ileri fun mi naa da? Bawo ni n o ṣe de ibẹ? Awọn eniyan n fi mi rẹrin, wọn n wipe, 'Abrahamu, baba orilẹ-ede pupọ, o ti pe ọdun mẹẹdogun bayi. O ti pe ọmọ ọdun marundinlaadọrun, tabi aadọrun ọdun. Nibo … gbogbo awọn ọmọ rẹ da? Ọmọ melo ni o ti bi bayi, iwọ baba orilẹ-ede pupọ?'” Ṣe ẹ ri i, wọn n fi ṣe yẹyẹ.

Ṣugbọn ko kọsẹ. O duro ti i. Wọn n ṣe yẹyẹ, wipe, “Baba orilẹ-ede pupọ, jẹ ki a ri i bayi. Ọmọ melo ni o ti bi ni akoko yii?” Ṣe ẹ ri i, wọn n fẹ lati ṣe yẹyẹ, nitoriti o di ileri Ọlọrun mu, o gbagbọ wipe O lee mu ileri Rẹ ṣẹ. O to bẹẹ, O ju bẹẹ lọ lati mu u ṣẹ. Oun ni … O lee pese ẹbọ fun ara Rẹ. Oun ni Jehofa-jire. O lee pese, O si lee la ọna fun ileri ti O ṣe. O fidi majẹmu naa mulẹ fun-un, nipa fifi han-an bi Oun yoo ti ṣe e - wipe Oun yoo mu Kristi, Oun yoo fa ẹmi Rẹ ya kuro lara rẹ, Oun yoo si fi ranṣẹ ni ikẹyin ọjọ…

57 A pari iyẹn ninu Iwe Mimọ ni ọsẹ yii lati fi iyẹn han fun yin, wipe a nilati fidi majẹmu yii mulẹ pẹlu iru-ọmọ alade Abrahamu, eyiti iṣe awọn eniyan lati inu awọn Keferi - kii ṣe awọn Juu - awọn eniyan lati inu awọn Keferi, nitori orukọ Rẹ̀, O mu wọn jade fun orukọ Rẹ̀. Ijọ ti o n jẹ orukọ Rẹ yoo pada sọdọ Rẹ, nitori ẹniti o jẹ niyẹn, ìyè rẹ ni.

58 Ẹ feti silẹ. Ni ọjọ Pẹntikọsti… Nigbati Ẹmi Mimọ ṣokalẹ ni ọjọ Pẹntikọsti, a fi iye fun ijọ. Ijọ naa jade lọ, wọn si ni… Wọn kọ iwe Iṣe Awọn Aposteli lẹyin ijọ naa, nipa ohun ti wọn ṣe, nitori Kristi ni o wa ninu awọn Aposteli.

Jesu sọ ninu iwe Johanu Mimọ ori kẹẹdogun, wipe, “Emi ni ajara, ẹyin si ni ẹka.” Ajara kii so eso; ẹka ni

o maa n so eso. Ajara maa n fun-un ni agbara ni. Njẹ ti ẹka naa - eyiti o kọkọ jade lati ara igi - ba mu iwe Iṣe Awọn Aposteli jade wa… Ti o ba tun yọ ẹka miiran, yoo jẹ igbe-aye kannaa.

59 Ni oṣu melo kan sẹyin, mo wa pẹlu ọrẹ mi ọwọn, John Sharrit, ni Phoenix. Tucson ni mo n gbe, gẹgẹbi ẹ ṣe mọ. Mo wa ni Phoenix. Arakunrin John Sharrit, arakunrin Kristẹni daradara … talaka gidi ni tẹlẹ, Oluwa si ti bukun fun-un…

Nigbati mo kọkọ lọ si Phoenix ni ọdun melo kan sẹyin, ko ni ọmọ kankan, o si n fẹ ọmọ. O talaka - o n siṣẹ loju titi, lati maa fọ okuta, fun bii kọbọ mẹẹdọgbọn si ọgbọn kọbọ ni wakati kan. O wá sibẹ. O si gba gbogbo ọrọ iṣẹ-iranṣẹ iwaasu yii gbọ. O wipe, "Ṣe iwọ yoo gbadura fun mi?" O ti bi ọmọ marun-un bayi.

60 Iyẹn pẹlu … yatọ si gbogbo iyẹn, nkan bii miliọnu mẹta si mẹrin dọla ni o maa n gbe kalẹ lọdọọdun fun iṣẹ ihinrere Kristi. Bẹẹ ni.

Mo wà pẹlu rẹ̀ nibẹ, laipẹ yii, mo n wo oko òwú rẹ̀. Odidi agbegbe kan ni o rà; ẹgbẹrun kan ati aabọ awọn eniyan Mexico ni o n ṣiṣẹ nibẹ. O si jẹ … ni ọdun mẹẹdogun sẹyin, o maa n fọ okuta fun kọbọ mẹẹdọgbọn ni wakati kan.

O mu mi lọ sinu oko ọsan rẹ̀, mo si ri igi kan ti o pani lẹrin ju ti mo tii ri ri ni gbogbo ọjọ aye mi. Iru igi kan ni - o ni oniruuru eso ni ori rẹ. Mo wo o. O ni eso ọsan didun, o ni ọsan kíkan, o ni eso ajara, o ni eso tanjariini, o ni eso tanjẹlo. Mo ro wipe oriṣi eso bii mẹsan ni o wa lori rẹ, tabi mẹwa. Mo wa ni, "Iru igi wo niyẹn?"

O ni, "Ah, iṣẹ iwadi kekere kan niyẹn, Arakunrin Branham."

Mo ni, "O ye mi." Mo ni, "Ṣe ori igi yẹn ni gbogbo wọn wa?" Mo ni, "Iru igi wo gan-an ni lati ilẹ wa?"

O ni, "Igi ọsan ni. Ọsan oní ìdodo ni."

Mo wa ni, "Ṣe bẹẹ ni?" Mo ni, "Kini awọn wọnyi n ṣe lori rẹ?"

O wipe, "A lọ́ wọn si ara rẹ ni."

Mo ni, "Ah, o ye mi." Mo ni, "O ye mi." Mo ni, "Njẹ ni ọdun ti o n bọ, gbogbo rẹ yoo pada di ọsan didun, tabi bẹẹkọ?"

O ni, "Ah, rara. Ọsan kikan yoo so eso ọsan kikan." O ni, "Eso ajara yoo so eso ajara, tanjariini yoo so tanjariini pẹlu."

Mo ni, "Lati ara igi ọsan didun?"

O ni, "Bẹẹni, sà."

Mo ni, "Emi ko mọ bi ẹ ti ṣe e."

O ni, "Eso ọsan ni gbogbo rẹ."

Mo ni, "O dara, iyin ni fun Oluwa! Mo ri nkankan."

61 Ẹ wo o. Ah, arakunrin! Nigbati Ẹmi Mimọ ba wọ inu ajara naa, ti o si so eso, lati ara ajara, si ara ẹka akọkọ, ti wọn si kọ iwe Iṣe Awọn Aposteli lẹyin rẹ, ti igi naa ba tun yọ ojulowo ẹka miiran, yoo so iru eso kannaa. Yoo jẹ Jesu Kristi.

Ni bayi, a ni ijọ Eleto, ijọ Alagba, Onitẹbọmi, ijọ Luther, ati ohun gbogbo, ti wọn lọ́ si ara rẹ̀, ti wọn si n so eso ijọ ẹlẹkọ-adamọ. Ṣugbọn ti o ba yọ ẹka miiran, yoo jẹ ẹka Ọrọ Ọlọrun ti o kun fun Kristi, ti o si tẹjumọ Kristi.

62 Ẹ ranti. Ṣe ẹ ranti iwaasu "Igi Iyawo", bi ẹnikẹni ninu yin ba gbọ fanran naa? Gẹgẹbi agbẹ naa ṣe wá, ti igi naa si n so eso ti ko dara. O ge e kuro, o tun ge e kuro, o ṣaa n ge e kuro. Ṣugbọn Joẹli wipe, "Ohun ti kokoro jewejewe kan jẹ kù, ni kokoro jewejewe miiran jẹ; ohun ti kokoro … kokoro jewejewe miiran jẹ ku, ni ohun miiran jẹ." A ri i wipe nkan kannaa ni gbogbo awọn kokoro wọnyẹn, o kan wá ni ipele ọtọọtọ ni.

Ohun ti ijọ Luther jẹ ku ni ijọ Eleto jẹ; ati ohun ti ijọ Eleto jẹ ku ni ijọ Onitẹbọmi jẹ; ati ohun ti ijọ Onitẹbọmi jẹ ku, ni ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ jẹ. Gbogbo rẹ ni wọn ti ge lulẹ.

63 Ṣugbọn Ọlọrun wipe, "Emi yoo mu bọ sipo, ni Oluwa wi, ani gbogbo ọdun naa. Emi yoo fi ijọ miiran ranṣẹ ni ikẹyin ọjọ. Emi yoo da ojulowo agbara naa pada. Ni akoko aṣalẹ, imọlẹ yoo wa."

Ni inu igi naa, bi o ti wu ki a ge ẹka rẹ kuro to, iru-ọmọ alade Abrahamu yoo jade wá. Halleluya! Ọlọrun ṣe ileri rẹ. Ọlọrun yoo ṣe e. O ni Oun yoo ṣe e. “Emi yoo mu bọ sipo, gbogbo ọdun ti awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti jẹ. Emi yoo da awọn ọdun naa pada. Emi ni mo ge ẹka rẹ kuro; ṣugbọn ẹka miiran yoo tun yọ lati ara igi naa. Yoo dabi igi ti a gbin si ipado omi, ani ẹniti n ṣe aṣaro ninu Ọrọ Ọlọrun tọsan-toru [kii ṣe ẹkọkẹkọ tabi ijọ ẹlẹkọ-adamọ], ṣugbọn ti o n ṣe aṣaro ninu Ọrọ naa tọsan-toru. Yoo dabi igi ti a gbin si ipado omi iye. Ewe rẹ ki yoo rẹ̀. Yoo maa so eso rẹ ni akoko rẹ.”

Ọlọrun ni o ṣe ileri rẹ.

64 Ọlọrun n fa ya, O n mu jade, O n ge e si wẹwẹ, O n ya ara Rẹ sọtọ, O n pin ara Rẹ. O ṣe nkan kannaa ni ọjọ Pẹntikọsti nigbati Ẹmi Mimọ sọkalẹ. Ọwọn ina yẹn sọkalẹ, eyiti o tẹle Israẹli. Gbogbo wa ni a mọ wipe Imọlẹ naa niyẹn. Kristi niyẹn. Nigbati O sọkalẹ ni ọjọ Pẹntikọsti, kini O ṣe? O pin ara rẹ, ahọn ina si ba le olukuluku wọn - Ọlọrun pin ara Rẹ sinu awọn eniyan naa.

Ah, arakunrin, ẹ lee ṣe alaipinya nipa Ẹmi kannaa ti o wa ninu Kristi. “Ẹniti o ba gba mi gbọ, iṣẹ ti mo ṣe ni oun naa yoo ṣe. Iṣẹ ti o ju iwọnyi lọ [tabi ti o pọ ju iwọnyi lọ, ni itumọ ti o tọ́] nitoriti emi n lọ sọdọ Baba. Ni igba diẹ si i, aye ki yoo ri mi mọ. Ṣugbọn ẹyin yoo ri Mi; nitori emi [ọrọ arọpo-orukọ ẹnikan], Emi yoo wa pẹlu yin, ani ninu yin titi de igba ikẹyin, titi de opin aye.” O ṣe ileri lati ṣe bẹẹ, iru ọmọ Abrahamu.

O wa nibi bayi.

65 A wa nibi, ni ọjọ melo kan sẹyin, a n ṣe ajọyọ ajinde Rẹ. Wipe Ọlọrun ji i dide, a jẹri si i, a kọrin nipa rẹ. O lee farahan ki O si ṣe nkankan ti O ṣe tẹlẹ, gẹgẹbi O ti ṣe ṣaaju ajinde Rẹ.

A n pe e ni alafọṣẹ, eṣu, Beelsebuubu, a lee jade kuro ninu awọn ijọ wa. Kini a ṣe iyẹn fun? Lati lee mu Iwe Mimọ ṣẹ ni: wipe ni igba ijọ Laodikea, Ọrọ naa, eyiti iṣe Kristi, ni a ti jade sita, O n kan ilẹkun, O n gbiyanju lati ri ifọwọsowọpọ lati ibikan, ki O lee wọle wá, ki O si fi ara Rẹ han.

66 Ṣugbọn ẹka kan yoo hu jade lati ibẹ, dajudaju. Mo sọ fun Arakunrin Sharrit, wipe, “Iru ẹka wo ni yoo yọ jade ni ọdun ti o n bọ? Ṣe yoo jẹ ti ọsan didun? Tabi ṣe yoo jẹ ti ọsan kikan?”

O ni, “Bẹẹni, yoo jẹ ojulowo.” “Nigbati o ba yọ ẹka miiran lati inu ara rẹ, yoo jẹ ọsan didun, gẹgẹbi o ti ri lati ilẹ wá.

Nigbati ojulowo iru aaye ti Abrahamu ba jade wa, Ẹmi ti o wa ninu Jesu Kristi yoo maa gbe inu wọn. Wọn yoo ṣe “Amin” si gbogbo Ọrọ naa. Wọn gba a gbọ. Kii ṣe, “A mí si eleyi, a ko mí si iyẹn”; gbogbo rẹ ni wọn gbagbọ, nitori Ọrọ Ọlọrun ni.

67 Ṣe ẹ gbagbọ ni aṣalẹ yii, pẹlu gbogbo ọkan yin? Amin. Mo ti waasu nibi yii titi ti mo fi ni … o ti pẹ́. Ẹ jẹ ki a tẹriba fun iṣẹju kan. Emi yoo pari eleyi ni alẹ ọla. Mo ṣe ileri wipe n ko ni da yin duro pẹ. Jesu Kristi, ọkannaa lana, loni, ati titi… O fidi rẹ mulẹ… O fidi rẹ mulẹ fun Abrahamu, nigbati o ri i nipa igbagbọ. O tẹsiwaju, ko ṣiyemeji nipa aigbagbọ. Ko kọsẹ. Iru-ọmọ alade rẹ nkọ? Awa ti a sọ wipe (awa Kristẹni ọjọ oni), ti a sọ wipe a mu ninu aago kannaa ti Oun mu, wipe a ni Ẹmi Rẹ kannaa ninu wa… A ri i ti o n fidi ileri naa mulẹ wipe Oun wa pẹlu wa,

68 ileri lati mu u ṣẹ…

Ko ri bẹẹ ri. Ninu gbogbo awọn iran ti o ti kọja, a ko ri iru rẹ ri. Ẹ wo gbogbo itan. Ko farahan ri. Nibo ni o si ti … nibo ni o yẹ ki o lọ ni ikẹyin ọjọ? Si ijọ ti a yanfẹ - kii ṣe si Babiloni, kii ṣe si Sodomu. Wọn ni ojiṣẹ kan lọdọ wọn. Ṣugbọn Ẹmi Mimọ ni ojiṣẹ si ijọ ti a yanfẹ.

Ni bayi, Ọlọrun n gbe ninu ẹran-ara eniyan, O n fi ara Rẹ han wipe Oun ni olumọ … Oun ni Ọrọ ti o n mọ ero inu ati ti ọkan, Jesu Kristi, ọkannaa lana, loni, ati titi lae. Oun ni Jehofa-jire. O ti pese ẹbọ wa ná, O si n fidi majẹmu Rẹ mulẹ. O n fidi majẹmu Rẹ mulẹ ni ikẹyin ọjọ yii pẹlu awọn eniyan.

69 Ẹyin ọrẹ, a lee fi gbogbo oru sọrọ. Ṣugbọn awọn nkan ti a ti sọ ti tó.

Awọn eniyan wà nihin ti wọn n saisan, ẹ nilo iwosan. Ẹ ko ha ṣe gba iyẹn gbọ? Ti mo ba lee wo yin san, emi yoo ṣe e. Ẹ maa gbadura. Ti mo ba lee wo yin san, emi yoo ṣe e. Emi ko lee wo yin san. Mo … ẹ kiyesi i wipe mo fi isin alẹ ọjọ kan tabi meji akọkọ sọ ori gbigbadura fun awọn alaisan. Kii ṣe fun iyẹn nikan. Bi iru-ọmọ kan ba wa nihin ti a yan tẹlẹ si iye, Ẹmi Mimọ yoo mu u. Wọn yoo ri i. Wọn yoo mọ ọ. Ni bayi, O…

Ẹni melo nibi yii ni yoo na ọwọ soke niwaju Ọlọrun, ki ẹ si wipe, “Mo gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan mi, wipe Jesu Kristi jẹ ọkannaa lana, loni ati titi lae; wipe O jinde kuro ninu oku, O si wa laaye laarin wa ni aṣalẹ yii, O n fi ara Rẹ han wipe Oun wa laarin wa, mo si gbagbọ wipe ti Ọlọrun ni”? Ṣe ẹ o na ọwọ yin soke, ki ẹ wipe, “Mo gba a gbọ nitootọ”?

70 Ni bayi, Baba wa ọrun, wọn n bẹ lọwọ Rẹ. Wọn n jẹwọ wipe iru-ọmọ Abrahamu ni awọn. Wọn n fẹ … wọn n fẹ ibukun Ọlọrun. Mo si ti sọ fun wọn ni ọna irọrun yii. Mo bẹrẹ lori akori ọrọ mi, n ko si lee pari rẹ. Ṣugbọn Baba, wọn ri i nibi ifidimulẹ fun Abrahamu, wipe O fidi rẹ mulẹ fun-un, O fun-un ni ifidimulẹ.

Njẹ ti Ẹmi Kristi ko ba si ninu wa, a jẹ wipe a kii ṣe ti Kristi. Iwa-ẹda Kristi ko si lee yipada. O si ti sọ fun wa, O ti ṣe ileri awọn nkan wọnyi fun wa bi Bibeli ti sọ, ni ibi pupọ. Majẹmu Laelae naa ṣe ileri rẹ ni Malaki ori kẹrin, bi yoo ṣe ri ni ikẹyin ọjọ; ti yoo yi ọkan awọn ọmọ pada si igbagbọ awọn baba, awọn baba Pẹntikọsti - ojulowo ẹkọ Bibeli, ojulowo Ọrọ - wipe ohun ti yoo ṣe niyẹn. Ati wipe ami kan yoo wà, ami yii ni yoo si fidi mulẹ … yoo fidi mulẹ nipa ohùn kan ti yoo tẹle e - wipe O wa nihin, awa si gba Ọ gbọ.

71 Ni bayi, Baba, jẹ ki Satani ki o kuro. Awa ko gbagbọ wipe a ni agbara kankan, Oluwa. A ko sọ wipe a ni agbara; ṣugbọn a sọ wipe a ni aṣẹ. A mọ wipe ọlọpa kekere kan loju titi, pẹlu fila ti o de si ori rẹ̀, ọkọ̀ nla kan yoo maa sare kọja ni oju titi pẹlu agbara nla - ko ni agbara kankan lati da eyikeyi ninu wọn duro. Wọn yoo lọ ọ luuluu ni.

Ṣugbọn jẹ ki o fi ami yẹn han, ki o si gbe ọwọ rẹ soke - awọn ijanu ọkọ yoo maa pariwo ni, awọn taya ọkọ naa yoo maa kun. Aṣẹ ni. Gbogbo ilu ni o ti i lẹyin. O ni aṣẹ; kii ṣe agbara. O tilẹ ma lee sanra, ṣugbọn o ni aṣẹ.

72 Bi o ṣe ri ni aṣalẹ yii niyẹn, Oluwa. A tọ Satani wa, kii ṣe pẹlu agbara, ṣugbọn pẹlu aṣẹ, a n fi ẹjẹ naa han, ati ifidimulẹ majẹmu naa. Ko ni ẹtọ lati de awọn alaisan wọnyi mọlẹ.

Mo n wo wọn, mo si ri i ti wọn n laagun, nibi yii… Ọlọrun o, bi ọna kan ba wa ti mo fi lee mu ọrọ naa tọ wọn lọ. Iba ṣe wipe wọn lee ri i ni, Oluwa, ani ki wọn da a mọ. Sọ wọn ji, Oluwa, lẹẹkan ni aṣalẹ yii. Jẹ ki wọn ri i wipe Iwọ ni Ọlọrun kannaa. O n fidi Ọrọ Rẹ mulẹ. O mu u ṣẹ gẹgẹbi O ti ṣe ileri. Ni ikẹyin ọjọ wọnyi, O sọ wipe awọn nkan wọnyi yoo ṣẹlẹ; pe nigbati a ba n fi Ọmọ eniyan han, awọn nkan wọnyi yoo ṣẹlẹ. Gba bẹẹ, Oluwa, jẹ ki wọn ri i wipe Iwọ ni. Ni orukọ Jesu ni mo gbadura. Amin.

73 Ijọ eniyan ti o dara ni yin. Mo ti lo kọja akoko mi, ṣe ẹ ri i, n ko ni i lọkan lati ṣe bẹẹ. Mo sọ fun wọn wipe n o tete jade ni aṣalẹ yii, ṣugbọn mo kuna lati ṣe bẹẹ nitori mo… Emi yoo pari akori ọrọ mi ni alẹ ọla, boya, ti Oluwa ba fẹ.

Awa niyi. Eniyan ni yin. Eniyan ni gbogbo wa. A fẹ wa laaye. Gbogbo eniyan ni o fẹ lo gbogbo akoko rẹ pe. Mo si gbagbọ wipe Ọlọrun fẹ ki a ṣe bẹẹ. Mo gba a gbọ. Ni bayi, kii ṣe wipe ko si ororo ikunra ni Gileadi. Ṣe ẹ mọ, wọn sọ ni igba kan wipe, “Eeṣe? Ṣe ko si ororo ikunra ni Gileadi ni? Ṣe ko si wolii nibẹ ni?” Isaiah sọ pe, tabi Elija sọ pe, “Ẹ lọ beere lọwọ rẹ. Ṣe nitori ko si wolii ni Israẹli ni? Eeṣe ti o fi lọ si Ekroni, nibẹyẹn, pẹlu oriṣa Beelsebuubu wọn? Eeṣe ti o fi goke lọ sibẹ (oun ti o jẹ Juu)? Eeṣe ti o fi goke lọ sibẹyẹn?” O ni, “Ṣe nitoriti ko si ororo ikunra ni Gileadi ni? Ṣe ko si oniṣegun nibẹ ni?”

Ṣe ko si … ṣe idi niyẹn? Ṣe idi naa niyẹn? Rara, sà. A ni ororo ikunra. Ẹmi Mimọ wa nibi. Bẹẹni, sà. Tiwa ni ileri naa. Ni bayi, ẹ nilati gba a gbọ. Ọjọ ti a wa yii jẹ ọjọ ti ọkan awọn eniyan ti daru, wọn ko… Aanu wọn ṣe mi. Wọn ko mọ ohun ti o yẹ ki wọn gbagbọ. Ẹnikan yoo sọ bayi, ẹlomiran yoo tun sọ bẹyẹn. “Jẹ ki ọrọ gbogbo eniyan jẹ irọ, ki temi si jẹ otitọ,” ni Oluwa Ọlọrun wi. Bẹẹ ni. Ko lee yi iwa-ẹda Rẹ pada.

74 Mo gbagbọ wipe a bẹrẹ kaadi adura 1 ni alẹ ana, tabi bẹẹko? A pe titi de 20 tabi nkankan bẹyẹn, huh? Ẹ jẹ ki a yi ilana yẹn pada. Ẹ maṣe jẹ ki a lo kaadi adura rara. Kiki … ẹyin ẹ ṣaa gbadura. Kaadi adura yoo fun ọ ni anfaani lati de oke nibi ni. Ṣugbọn mo ni imọlara ifarahan rẹ, nitorinaa, mo mọ wipe O wa nibi.

Ẹni melo ni o ti ri fọto angẹli Oluwa yẹn ri? Ki Ọlọrun ran mi lọwọ, nigbati mo ba pade yin nibi idajọ, ko to ẹsẹ bata meji si ibi ti mo duro si yii. Bẹẹ ni, O wa nihin.

75 Ẹnikan ti ko ni kaadi adura, na ọwọ rẹ soke, ki o wipe, “Emi ko ni kaadi adura, sibẹ mo n ṣaisan, mo si ṣe alaini.” Ọwọ lọ soke nibigbogbo. Ko buru.

Mo fẹ sọ fun yin bayi. Kini angẹli yẹn ṣe loke ibẹyẹn ni igba yẹn? O yi ẹyin rẹ pada …o kọ ẹyin si Abrahamu, mo fẹ de ibẹyẹn ni aṣalẹ yii, ṣugbọn n ko lee ṣe e … nibiti O ti sọ wipe yoo ri bakannaa ni igba bibọ Oluwa gẹgẹbi o ti ri ni Sodomu. A ri i wipe o kọ ẹyin rẹ si agọ. Sarah si rẹrin si ohun ti O sọ, nitoriti O sọ fun-un, ko si ye e - wipe ọkunrin kan ni ita nibẹyẹn ti o n jẹ ẹran ti oun din, ti o si n mu wara lati ara maaluu, ti o si n jẹ ẹran ara rẹ̀. Ọlọrun si niyẹn.

76 Bibeli wipe Oun ni.

Abrahamu sọ pe Ẹlohimu ni. Bẹẹ ni. Ẹlohimu, Ọlọrun. O parẹ mọ Abrahamu loju. Ọlọrun si pe e ni Oluwa Ọlọrun Ẹlohimu, Ẹniti o danikan to funra rẹ. “Ni atetekọṣe…” a lo ọrọ yii kannaa. Gbogbo ọmọwe ni o mọ iyẹn. “Ni atetekọṣe, Ọlọrun…” Ẹ wo ede Heberu yẹn. “Ẹlohimu.”

77 Ẹ kiyesi igbati Abrahamu sọ pe, “Oluwa Ọlọrun Ẹlohimu” - ọkunrin kannaa ni, ẹni kannaa ni, O n fihan wipe Ọlọrun yoo fi ara Rẹ han ninu ẹran-ara eniyan fun iru-ọmọ Abrahamu, lati fidi majẹmu naa mulẹ, ki O si ṣe nkan kannaa ti O ṣe. Ṣe o ye yin? Nkan kannaa ni O ṣe nibẹyẹn. O jẹ wolii ti o n mọ ero ọkan ati ti inu nitori…

Ẹni melo ni o mọ wipe Bibeli sọ pe Ọrọ Ọlọrun n mọ ero inu ati ti ọkan? Ni bayi, ti Ọlọrun ba mu eniyan mẹta nibi yii ni aṣalẹ yii… Ipenija ni eyi jẹ. Ti ẹnikẹni ko ba ro bẹẹ, iwọ wa ṣe e. Ti o ko ba lee ṣe e, maṣe sọ ohunkohun nipa rẹ nigbanaa. Ẹ kiyesi i bayi. Mu eniyan mẹta - mẹta jẹ ifidimulẹ - ti wọn jẹ ajeji patapata, ti Ẹmi Mimọ ba si lee… Ti ẹ ba ṣaa lee gbagbọ. Gbogbo ohun ti mo beere lọwọ yin niyẹn (lati gbagbọ) wipe ki ẹ ṣe, ni ki ẹ gbagbọ wipe otitọ ni Bibeli yii, ati wipe a ti wa ni ikẹyin ọjọ, ati wipe ileri ikẹyin ọjọ niyi.

78 Ẹ ranti, Abrahamu, tabi ẹnikẹni, ko ri ami miiran, titi di igba ti ọmọ ileri naa fi farahan. Abrahamu ri oriṣiriṣi awọn nkan, titi di igba yẹn. Ṣugbọn ami ti o kẹyin niyẹn. Ki yoo ṣẹ́ ẹ, itẹsiwaju Ọlọrun ni. Iru-ọmọ Abrahamu, ami wọn ti o kẹyin niyẹn, ṣe o ye yin. Eyi ti o kẹyin niyẹn… Ọlọrun … lojukannaa, o mọ wipe Ẹlohimu niyẹn. Jesu si wá, O wipe iyẹn yoo ri bẹẹ, a si wa nibẹ loni, nkan kannaa ni. Ẹyin eniyan, otitọ ni.

Mo mọ… O lee wipe, “Ọlọrun ninu aba oko kekere yii kẹ?” Bi o ṣe maa n ri nigbagbogbo niyẹn. A bi Oun ni ibujẹ ẹran. Ko tilẹ si ẹniti o gba a gbọ. Ṣugbọn kiki awọn iru-ọmọ nikan ni o gbagbọ, ti a ti yan tẹlẹ si iye, awọn nikan ni. “Gbogbo awọn ti Baba ti fi fun mi yoo tọ mi wa.” Bẹẹ ni. O ko nilo lati daamu nipa iyẹn. Ti orukọ wọn ba wa nibẹ, wọn yoo ri i, ati pẹlu… Wọn yoo ṣe e.

79 Ati - ọkunrin miiran nibẹyẹn, oun ati ọmọ rẹ kekere, ni alẹ ijelo, wọn ro wipe o ti ku ni. Mo wa ni Beaumont. Wọn pe, a si lọ sibẹ. O gbe ọwọ rẹ le mi, o bẹrẹ si sọkun, o ni, “Arakunrin Branham, Ọrọ Oluwa wa pẹlu rẹ. Ṣaa beere lọwọ Rẹ.” Ni iṣẹju yẹn, ọmọ-ọwọ naa jinde pada, o si wa laaye. Baba rẹ ni o joko si ibẹyẹn, iranṣẹ Ọlọrun ni.

Ọkunrin yii, ti o ni ijamba ọkọ, ọkọ naa sọ ọ sinu ibikan, sinu koto kan, o si pa ọpọlọ rẹ lara, ati awọn nkan miiran. Oluwa wo o san, patapata. Wọn gbagbọ. Patapata, wọn…

80 Ẹ maṣe sọ wipe emi ni mo ṣe e. Emi ko ni nkankan ṣe pẹlu rẹ. Igbagbọ wọn ninu Ọlọrun, oun ni o ṣe e. Ṣe o ye yin? Ẹ ni igbagbọ! Gbogbo…

Jesu sọ, ninu iwe Marku Mimo 11:22, “Ohunkohun yoowu! Ti ẹyin ba wi fun oke yii pe, 'Ṣidi,' ti ẹ ko si ṣiyemeji ninu ọkan yin, ṣugbọn ti ẹ gbagbọ wipe ohun ti ẹ wi yoo ṣẹ, yoo ri bẹẹ fun yin.” Bi o ṣe ri niyẹn, ṣe o ye yin. Kii ṣe ireti; mo “mọ ọ” ni.

Ti Ó ba lee fi ara Rẹ̀ han wipe Oun wa laaye, ti Ẹniti o ṣe ileri naa ba lee fidi rẹ mulẹ wipe Oun wa laaye, ko si ohun kan ninu aye yii ti o lee ṣe e. Ẹ ji giri! Ẹ gbọn ara yin jigi gidigidi, ani ẹmi yin. Ṣe o ye yin? Ko si ohun ti o lee ṣe e ni aye yii bikoṣe Ọlọrun.

Ni bayi, o lee - o lee pe e ni eṣu ti o ba fẹ. Awọn naa pe e ni eṣu, wọn si tun lee pe Ẹmi Rẹ ni eṣu naa. Wọn ni, “Eṣu ni o n ṣe iyẹn.” Ko buru, wọn gba ere rẹ.

Iwọ ṣaa gbagbọ. O ko lee wo ni san. Emi naa ko lee wo ni san. Ko si eniyan ti o lee wo ni san. Ọlọrun ni oluwosan.

81 Ṣugbọn ti o ba ṣaa lee mọ wipe Ẹni naa ti o n sin, nitori ẹniti o ṣe ya ara rẹ kuro ninu aye lati sin-in, Ẹni naa ti o fẹran; Ẹni naa ti yoo duro nibi Idajọ, iwọ yoo wa nibi Idajọ pẹlu Rẹ, lati gba idajọ, ti ifarahan Rẹ ba lee wa sibi yii, ki o si fihan wipe Oun wa nihin!

Ara-iyara Rẹ ko lee ṣe e. Nigbati iyẹn ba de, o pari niyẹn. “Gẹgẹbi manamana ti i kọ lati Ila-oorun titi de Iwọ-oorun, bẹẹni bibọ Ọmọ eniyan yoo ri.” Ṣugbọn Ẹmi Rẹ!

Ijọ si ti wa, ẹ wo bi o ṣe dagba; nipasẹ idalare, isọdimimọ, baptisiimu Ẹmi Mimọ; ni bayi, akoko igbasoke ti to, lati pese Ijọ silẹ. Gẹgẹbi o ti ṣe ileri gan-an niyẹn, gẹgẹbi a ti ṣeto awọn Igba Ijọ, a ti ri iyẹn, ohun gbogbo ti n wa si ilẹ.

Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ni ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti o kẹyin. Iyẹn wa ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ. Oun ni yoo jẹ ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti o kẹyin, ti a kọ̀ pẹlu awọn ti o kù; idi niyẹn ti ijọ ẹlẹkọ-adamọ fi wà. Ko si ijọ ẹlẹkọ-adamọ kankan ti o ṣe itẹwọgba niwaju Ọlọrun. O jẹ… Ẹnikọọkan ni o ṣe itẹwọgba niwaju Ọlọrun.

82 Ṣe ẹ ko lee gbagbọ wipe Ifarahan Rẹ wa nibi ni? Arakunrin yin ni mo jẹ, a si ran mi bayi, Ọlọrun sọ fun mi wipe ki n wa ṣe nkan yii. Nitorinaa, mo gba a gbọ. Ti a ko ba kọ ọ sinu Ọrọ naa fun iran yii, emi yoo kuro nibẹ ni. Ohunkohun ti ko ba si ninu Ọrọ yẹn, emi ko gba a gbọ. Emi - Emi ki yoo gba a. Emi ko sọ wipe emi ki yoo gba a gbọ, ṣugbọn n ko ni gba a; ko ye mi. Ṣugbọn nigbati o ba wa ninu Ọrọ naa, ti o si jẹ ileri fun iran yii, iyẹn ye mi. Iwọ nkọ? [Ijọ sọ pe, “Amin.”] Ki Oluwa ran wa lọwọ bayi. Ẹ ṣaa… Ẹ na ọwọ jade bayi nipa

igbagbọ, ki ẹ gbagbọ wipe ninu… ifarahan wa… wipe iwaju Jesu kannaa ti o ṣe ileri yẹn ni a wa bayi.

83 Ninu Bibeli, Pọọlu ti a mí sí, ẹniti o ni ifihan pupọ tobẹẹ ti ara rẹ ko balẹ, “O ni ẹgun kan ninu ara rẹ̀, ki o ma baa gberaga nitori ọpọlọpọ awọn iṣipaya ti o ni.” Ṣe ẹ ri i, o kọ Bibeli, o ni imisi pupọ tobẹẹ. O kọ awọn Iwe inu Bibeli. Bii Mose, oun naa jẹ wolii. Nitorinaa, Ọrọ naa tọ ọ wa, o si kọ Ọ, a fi aaye fun-un ninu Iwe Mimọ, ani awọn Akọsilẹ mimọ naa. Oun ni ẹniti o - ti o sọ pe… ti o gba nkan yii gbọ, o si kọni ni nkan wọnyi.

84 Ẹ ranti wipe Kristi jinde kuro ninu oku, O si n bẹ laarin wa. Ẹ fi iyẹn si ọkan yin, Kristi jinde kuro ninu oku, O si n bẹ laarin wa.

A ti ri oriṣiriṣi awọn iṣẹlẹ nla, ariwo pipa ati yinyin Ọlọrun; gbogbo rẹ ni o dara. A ti fedefọ, a ti sọtẹlẹ, ati ohun gbogbo bẹẹ. A ti ri gbogbo iyẹn. Iyẹn dara. Iyẹn naa lọ pẹlu rẹ.

Ṣugbọn ẹ ranti, ohun ti o kẹyin ni Ifarahan Rẹ lati ọrun wa, ani Ọrọ naa funra Rẹ. Oun ni Ọrọ naa. Ori, ti iṣe Ọrọ naa, n bọ wa ba Ara. Ṣe o ye yin? Lẹyin eyi, Ọrọ naa, ni Heberu ori kẹrin, wipe, “Ọrọ Ọlọrun mu ju idakida oloju meji lọ, o si n pin ọkan ati ẹmi niya.” Ẹ mu ẹṣẹ Iwe Mimọ yẹn, ki ẹ yẹ ẹ wo lọ si ibẹrẹ awọn wolii, ki ẹ wo o lọ si igba Jesu Kristi, ki ẹ si wa wo o boya kii ṣe nkan kanna, nkan kannaa, eyiti a fi mọ wipe Oun ni Messiah.

Ko si eniyan kankan nibi yii ti o jẹ Messiah. Ẹmi Mimọ ni Messiah. Kristi ati Ẹmi Mimọ, ọkannaa ni wọn, nitorinaa, O wa nibi nisisiyi, O n ṣiṣẹ ninu ara, O n pese Ara naa silẹ fun oore-ọfẹ igbasoke. Ẹ gba a gbọ, ẹyin ọrẹ.

Oluwa Ọlọrun, jọwọ jẹ ki o ṣẹlẹ ni aṣalẹ yii.

85 Ni bayi, ni orukọ Jesu Kristi, mo fi gbogbo ẹmi ti o wa nibi yii si abẹ akoso mi, fun ogo Ọlọrun. Mo sọ bẹẹ ki o lee ye yin ni. Ṣe ẹ mọ, iwọ maṣe…

Ti o ba n ṣiyemeji, iwọ - iwọ, ko dara ki o duro pẹ, nitori ko si iyemeji wipe ọpọlọpọ awọn ero ti o joko si ibi yii ti ri ohun ti o n ṣẹlẹ si awọn alaigbagbọ nigbamiran. Yoo kuro lati ara ẹnikan, yoo si wọ inu ẹlomiran, gẹgẹbi o ti ṣe ninu Bibeli.

86 Ẹni melo ninu yin ni o n gbadura, ti o si mọ wipe ajeji ni mi, wipe n ko mọ ohunkohun nipa rẹ? Na ọwọ rẹ soke, wipe o n gbadura, o mọ wipe n ko mọ ohunkohun nipa rẹ.

Iwọ, ọkunrin ti o joko si ibẹyẹn pẹlu tai dudu, ti o n wo mi nibi yii.

Ẹ wo o bayi. Ṣe ẹ ri Imọlẹ naa? Ṣe ẹ ko ri I ni? Àwọ̀ ina ni o ni, bii àwọ̀ wura ati ti eweko ni Imọlẹ naa ti o wa nibẹyẹn!

Ṣe o gba mi gbọ wipe iranṣẹ Rẹ̀ ni mo jẹ, sà? Ti Ọlọrun ba lee fi ohun ti o jẹ iṣoro rẹ han mi, ṣe o gbagbọ, ṣe iwọ yoo gba mi gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, iwọ yoo gbagbọ wipe Ọlọrun ni? Ṣe iwọ yoo ṣe bẹẹ? Ṣe iwọ yoo gbagbọ wipe iwosan rẹ yoo de? Ṣe o ni kaadi adura? Rara, o ko ni. O ko nilo rẹ. Eti ni o n dun ọ. Ti o ba ri bẹẹ, na ọwọ rẹ soke. Inu eti rẹ ni o wa tẹlẹ; ko si nibẹ mo bayi, ti o ba gba a gbọ. Emi ko mọ ọkunrin naa ri, n ko ri i ri.

87 Ọkunrin kan ni o joko si ẹgbẹ rẹ yii. O n gbadura. O n gbadura fun nkankan ti o n ṣe e. Wo mi, sà. Ṣe o ni kaadi adura? [Arakunrin naa wipe, “Rara.”] O ko ni. Ṣe o gba mi gbọ wipe iranṣẹ Ọlọrun ni mi? [“Bẹẹni”] Ṣe o gba ohun ti mo sọ fun ọ gbọ, wipe Otitọ ni? [“Bẹẹni, sà.”] Ṣe o gbagbọ wipe Ifarahan Jesu Kristi ni? [“Bẹẹni, sà.”] Ṣe o gbagbọ wipe ẹyin rẹ yoo gba imularada lati isisiyi lọ? O gbagbọ? Na ọwọ rẹ soke. Ti iwọ yoo ba gbagbọ! Ṣe ẹ ri i?

Ẹ beere lọwọ ọkunrin yẹn. Emi ko ri i ri ni gbogbo ọjọ aye mi. Emi kọ ni o fi ọwọ kan. O jinna si mi ni ogun ẹsẹ bata. Kini o fi ọwọ kan? Iyẹn ni o mu Iwe Mimọ ṣẹ. Olori Alufaa ni o fi ọwọ kan. Ibẹyẹn ni o joko si, o n gbadura wipe ki a wo oun san. Ṣe ẹ ri i, Olori Alufaa ni o fi ọwọ kan, ẹniti o mọ ailera wa. Ṣe o ye yin?

88 Kini o ro, iwọ ọdọmọkunrin ti o joko si ẹyin ibẹyẹn, ọdọmọkunrin kan ti o n wo mi taara? Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun ti wo aisan kindinrin ti o ni yẹn san? O gbagbọ? Na ọwọ rẹ soke, ti o ba gba a gbọ. Ṣe o fẹ dẹkun aṣa ti o ni yẹn pẹlu, ki o sọ awọn siga naa sigbo? Ju ọwọ rẹ bayi ti o ba fẹ ṣe bẹẹ. Fi silẹ nigbanaa, ki o si gbagbe rẹ. Jesu Kristi ti wo ọ san. Ti o ba lee gbagbọ!

Ni odikeji ibi ti o wà, obinrin kan joko sibẹ, pẹlu awò-ojú ni oju rẹ. Aibalẹ ara ni aisan ti o n ṣe e. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo ọ san, arabinrin? Na ọwọ rẹ soke, ti o ba gba a gbọ. O dara.

Ṣe o lee ṣe oore kan fun mi? Obinrin kan joko si ẹgbẹ rẹ, aisan obinrin ni o n ṣe e, aisan obinrin. Bẹẹ ni, arabinrin. Na ọwọ rẹ soke, ti o ba ri bẹẹ. Isun ẹjẹ. Gbe ọwọ rẹ le e, ki ara rẹ lee da, nitoriti o gbagbọ.

89 Ẹniti o tun joko si ẹgbẹ tirẹ naa, eni, eji, Oun ni o wa lori obinrin ti o joko si ẹgbẹ rẹ yẹn. Ẹsẹ ni o n dun-un, o ni iṣoro pẹlu ẹsẹ rẹ. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo ẹsẹ rẹ san? Na ọwọ rẹ soke. Oun niyẹn. Ṣe ẹ ri i?

Ṣe ẹ gbagbọ wipe Oun ni Jesu Kristi, ọkannaa lana, loni, ati titi lae? [Ijọ sọ pe, “Amin.”]

Ṣe o gbagbọ, iwọ ti o joko si ibẹyẹn? Lẹyin ọkunrin ti o joko si iwaju yii, obinrin ti o joko si ibi yii? Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun… Ohun meji ti o lewu ni o n ṣe ọ. Ọkan ninu wọn ni arun jẹjẹrẹ; ekeji ni aromọleegun. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo ọ san. Ti o ba lee gbagbọ, na ọwọ rẹ soke, ki o wipe, “Mo - mo gbagbọ.” Ko buru, gbagbọ.

Ṣe ẹ gbagbọ? O n fidi majẹmu naa mulẹ.

90 Obinrin kan ni o joko si ibi yii, ti o n wo mi, lẹyin ọkunrin yii. Aṣọ pupa ni o wọ. Pupa, nibi yii; ó lee jẹ aṣọ otutu. O jinna pupọ; a ko riran ri ibẹyẹn daradara. Nkan yẹn si maa n ko aarẹ ba ni, gbogbo nkan ṣaa n yipada bii awọ wara ni gbogbo inu ile yiii ni.

Ṣugbọn oun niyẹn, o wa ni ori rẹ. Ṣe ẹ ri Imọlẹ yẹn? O n gbadura nipa nkankan. Ti Jesu Kristi ba fi ohun ti o n gbadura nipa rẹ han mi, ṣe iwọ yoo gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? Iwọ yoo gbagbọ? Ajeji ni mọ jẹ si ọ, iwọ naa si jẹ ajeji si mi. Ṣugbọn o ti fi ọwọ kan Olori Alufaa naa, nitori ami ti O fi fun mi wa ni ori rẹ̀, ṣe ẹ ri ami naa. Mo mọ bẹẹ.

O ni arun aibalẹ ara ti o le, eyiti n da ọ laamu. Bẹẹ naa ni o tun ni gbẹgbẹ ni ọfun rẹ, eyiti o n da ọ laamu. Ti o ba ri bẹẹ, na ọwọ rẹ soke.

O sọ pe, “O lee ri iyẹn.”

91 O dara, iwọ wa… Kii ṣe ibi ni o ti wa. O wa… Kii ṣe agbegbe yii ni o ti wa. Lati Memphis ni o ti wa. Bẹẹ ni.

Obinrin ti o joko si ẹgbẹ rẹ, lati Memphis ni oun naa ti wá. Ṣe o gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, arabinrin? O gbagbọ wipe Ọlọrun lee wo ọ san? Ṣe o gba mi gbọ wipe mo jẹ wolii Rẹ, tabi iranṣẹ Rẹ? Iyẹn maa n mu awọn eniyan kọsẹ, ṣe ẹ ri i. Ṣe o gba mi gbọ wipe iranṣẹ Rẹ ni mi? O gbagbọ wipe Ọlọrun ni o n sọ awọn ọrọ wọnyi? O mọ wipe emi ko lee mọ ohunkohun nipa rẹ. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun ni nigbanaa? O dara. Gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Ohun ti o n ṣe ọ ni wipe, o ni… o ni iṣoro pẹlu ọfun rẹ pẹlu. Ohun miiran, o ni koko kan ti o wu si ẹgbẹ rẹ. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee sọ ẹgbẹ ibi ti o wà fun mi? Ti o ba ri bẹẹ, na ọwọ rẹ soke ti o ba jẹ otitọ ni mo n sọ fun ọ. Ẹgbẹ ọtun ni o wà. Ṣe ẹ ri i? Ṣe ẹ ri i? Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee sọ ẹniti o jẹ fun mi? Ṣe iyẹn yoo ran ọ lọwọ? Iyaafin Cox ni ọ. Bẹẹ ni. Ṣe ẹ ri i. Maa pada lọ, ṣe ẹ ri i.

Ṣe ẹ gbagbọ? Ṣe gbogbo yin gbagbọ bayi? [Ijọ n yọ, wọn sọ pe, “Amin.”] Ifidimulẹ majẹmu naa niyẹn, fun Iru-ọmọ Abrahamu, ti ẹ ba lee gbagbọ! Ṣe o ye yin?

92 Obinrin kan niyi ti o dubulẹ sori ibusun aisan. Ṣe o lee gbọ mi, arabinrin ti o dubulẹ sori ibusun aisan yẹn? Bẹẹni. Emi ko lee wo ọ san. Emi ko mọ ohunkohun nipa rẹ; ajeji ni o jẹ si mi. Ṣugbọn ṣe o gbagbọ wipe Jesu Kristi lee fi ohun ti o n ṣe ọ han mi? Ṣe iyẹn yoo ran ọ lọwọ? Ṣe yoo ran ọ lọwọ? Ti o ba dubulẹ si ibẹyẹn, iwọ yoo ku. Anfaani kanṣoṣo ni o ni lati wa laaye, iyẹn ni ki o gba Kristi. Arun jẹjẹrẹ ni o ni. Bẹẹ ni. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo mu ọ lara da bayi? Ṣe o gbagbọ? Na ọwọ rẹ soke, ti o ba gbagbọ. O dara. Ni ibi ti o wa yẹn, ohun kan ti o lee ṣe, ni wipe ki o dide kuro ninu ibusun yẹn; ki o si gbe ohun ti o sun le, ki o maa lọ si ile, ki o gba igbagbọ rẹ ninu Ọlọrun, gẹgẹbi Iru-ọmọ Abrahamu. Dide duro, ni Orukọ Jesu.

Ṣe ẹ ri i, o ti dide, lati gba ileri rẹ ninu Ọlọrun.

93 Melo ninu ẹyin ti o ku ni o gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan yin bayi?

Dide duro. O ni okun; Ọlọrun yoo fun ọ ni okun. Dide duro lori ẹsẹ rẹ. Oun niyẹn, o ti dide kuro ninu ibusun aisan naa.

Ẹyin ti o ku ti ẹ fẹ gba Jesu Kristi, ẹ dide duro lori ẹsẹ yin. Ẹ dide duro lori ẹsẹ yin. Ẹ dide, nibigbogbo, ẹ gba Jesu Kristi gẹgẹbi oluwosan yin.

Jesu Oluwa, mu gbogbo wọn lara da. Gba bẹẹ, Oluwa.

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7